Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 11-31 | jan./ jun.2025.

# Ewì Alohùn Nínú Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá: Ìwé Eré-onítàn Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀ tí Láwuyì Ògúnniran kọ bí Àpẹẹrẹ

# Poemas na literatura iorubá: A história do filho do profeta, de Lawuyì Ógúnnirán

**Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọlálérè ADÉYẸMÍ, PhD***
ORCID iD https://orcid.org/0000-0003-2299-1012

**ÀṢAMỌ̀ (Yoruba)**
Àwọn onímọ̀ tíọ̀rì ìjẹmọ́pọ̀ àṣà ti fidì rẹ̀ múlẹ̀ pé kò sí àwùjọ tí kò ní àṣà tirẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni káríayé bí aṣọ onísúgà ni ìṣẹ̀ṣe jẹ́ sí gbogbo orílẹ̀-èdè ayé. Kò síbi tí a kì í gbé dáná alẹ́, ọbẹ̀ lè dùn jura wọn lọ. Inú àṣà lá sì ti fa lítíréṣọ̀ jade fún àǹfààní àti ìgbádùn àwọn ènìyàn àwùjọ tí ó ni àṣà náà. Ọ̀nà méjì à ń gbà gbé lítíréṣọ̀ jade lágbààyé, a lè sọ lẹ́nu, kí ó jẹ́ eré ẹnu, ó sì lè jẹ́ àpilẹ̀kọ. Èyí tí a ń sọ lẹ́nu ló wọ́pọ̀ jù ní ilẹ̀ Afirika. Òun ni à pè ní lítíréṣọ̀ alohùn lóde-òní dípò lítíréṣọ̀ àtẹnudẹ́nu tàbí àbáláyé tí à ń pè é tẹ́lẹ̀. Púpọ̀ nínú àwọn onímọ̀ iṣẹ́ lámèyítọ́ ló ti wo ipò àti ipa tí ewì alohùn Yorùbá ń kó nínú lítíréṣọ àpilẹ̀kọ Yorùbá àti ìjẹyọ rẹ̀ nínú ìwé èré-onítàn ṣùgbọ́n abala tí a wò ló jẹ́ tuntun èyí ni ìṣàmúlò ewì alohùn nínú ìwé eré-onítàn ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* tí Láwuyì Ògúnniran kọ. Àwọn onísẹ́ lámèyítọ́ kò tíì fi bẹ́ẹ̀ wo ipò àti ipa tí ewì alohùn kó nínú eré yìí bí wọ́n ṣe wo àwọn ìwé eré-onítàn ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn yòókù. Nítorí náà, èròǹgbà wa ni láti ṣe àgbéyẹ̀wò ìṣàmúlò ewì alohùn nínú eré náà. Ọgbọ́n ìṣèwádìí tí a lò ni agbàlàyé (Descriptive method), a dìídì yan ìwé eré-onítàn *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* láàárín àwọn eré ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn nítórí pé iṣẹ́ lámèyítọ́ kò tíí pọ̀ lórí rẹ̀. A ṣe àmúlò tíọ̀rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn nítorí ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá tó kún fún ìjìnlẹ̀ ohùn ẹnu Yorùbá ni, ó sì dálé ìtàn ogun. Àbọ̀ ìwádìí fihàn pé bí àmù omi ńlá ni ewì alohùn Yorùbá jẹ́ fún eré-onítàn àpilẹ̀kọ, èyí tí àwọn òǹkọ̀wé òde-òní ti ń bù mu, tí wọ́n sì ń bù wẹ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n ń dárà sí iṣàmúlò rẹ̀; a rí ìjẹyọ òwe, oríkì, àwíṣe bí ọfọ̀, ààsán, ayájọ́, èpè àti orin nínú ìgbékalẹ̀ àti àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó eré, ìfìwàwẹ̀dá, ìlò èdè, kókó-ọ̀rọ̀. Ìkádìí rẹ̀ ni pé òpìtàn pàtàkì ni Alàgbà Láwuyì Ogunniran, akéwì ìsẹ̀ǹbáyé tó jinlẹ̀ nínú ewì alohùn Yorùbá ni, ó sì fi ìwé *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* pàrokò sí ìran Yorùbá pé kí wọ́n jáwọ́ lápọ̀n tí ò yọ̀, kí wọ́n gbómi ilá kaná, kí wọ́n wà ní ìrẹ́pọ̀ láìjà mọ́, kí ọ̀mọ aláte ìlẹ̀kẹ̀ má bàá dọmọ aláte ọ̀rúnlá àti pé kí ewì àlohùn Yorùbá ó wà títí láé fún ìran tó ń bọ̀ lẹ́yìn.

**AWỌN KOKO**
Oriki, Litireso, Ede Yoruba

**RESUMO (Português)**
Os estudiosos da linguística confirmaram que não existe sociedade que não tenha sua própria língua e, no mundo, como língua comum, ela é usada por todas as nações. Não há lugar onde não vivamos e possamos apreciá-la. E a literatura tem sido produzida a partir da língua para o benefício e o prazer das pessoas da sociedade que a possui. Há duas maneiras pelas quais a literatura é transmitida ao mundo: ela pode ser falada, como forma de entretenimento, e pode ser usada como ferramenta. A língua falada é a mais comum na África. É chamada de literatura oral moderna, em vez de literatura oral ou literária, como era chamada anteriormente. Muitos estudiosos examinaram o papel e o lugar da poesia oral iorubá na tradição literária iorubá e seu uso na ficção histórica, mas o

* Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilọrin, Ilorin Nigeria, E-mail: adeyemiolalere@yahoo.com

aspecto que estamos examinando é novo, ou seja, o uso da poesia oral no romance de ficção histórica Omo Aláte Îleke, escrito por Lawuyì Ògúnnirán. O papel e a função da poética nesta peça não foram examinados por estudiosos como em outros dramas históricos. Portanto, nosso objetivo é examinar o uso da poética na peça. O método de pesquisa utilizado é descritivo, e escolhemos especificamente a peça Omo Aláte Îleke entre os dramas históricos porque não há muitos trabalhos acadêmicos sobre ela. A teoria da ficção histórica é usada porque a história da nação iorubá é repleta da profundidade da língua iorubá e é baseada na história da guerra. Pesquisas mostram que a poesia iorubá é como um grande reservatório para o drama histórico, que os escritores modernos têm bebido e ainda bebem, embora sejam bons em seu uso; vemos o uso de provérbios, poesia, provérbios como ofo, àasan, ayájo, épe e canção no desenvolvimento e desenvolvimento da história, o cenário do drama, a criatividade, o uso da linguagem, o tema. Sua conclusão é que o Ancião Lawuyì Ogunniran é um grande historiador, um poeta profundamente enraizado na poesia iorubá, e ele escreveu o livro Ọmọ Alátẹ Ìlẹkẹ, no qual ele exortava a geração iorubá a se libertar do mal, a se libertar do mal, a se libertar do mal, para que o mal do passado não seja esquecido e que a poesia iorubá permaneça para sempre para as gerações futuras.

**PALAVRAS-CHAVE:**
Poema, Literatura, Lingua Yoruba

**Ìfáárà**

Ní ilẹ̀ Afíríkà kí ètò ìkónilẹ́rú, àti ìmúnisìn tó bẹ̀rẹ̀, ipò pàtàkì ní lítíréṣọ̀ àlohùn wà, ipa tó sì ń kó láyé ijọ́sí kò kéré. Ẹ̀ka mẹ́ta ló pín sí, ewì alohùn, ìtàn ọlọ́rọ̀ geere àti eré-oníṣe àtayébáyé. Ọ̀nà ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ ni wọ́n jẹ́. Bí àwọn adúláwọ̀ ṣe ń kọ́mọ wọn láṣà àti ìṣe wọn ni láti ìran dé ìran ló wà nínú lítíréṣọ̀ alohùn. Nígbà tí ètò ẹ̀kọ́ mọ̀ ọ́n kọ-mọ̀ ọ́n kà dé ni lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ bẹ̀rẹ̀. Ẹka ewì alohùn ni àfojúsùn wa nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí. Nínú ewì alohùn ni àwọn Yorùbá ti ń fi èrò báyéṣerí wọn hàn, ìrònú wọn, lórí àyíká wọn, èrò ọkàn wọn lórí ohun gbogbo, ìwòye, ojú àmúwayé àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò ìran Yorùbá lórí ìbáragbépọ̀, ẹ̀sìn, ìṣèlú, àṣà, ìṣẹ̀ṣe, ẹ̀kọ́, iṣẹ́, ètò ọrọ̀-ajé àti ohun gbogbo tó jẹmọ́ ìgbésí ayé wọn, inú ewì alohùn wọn ló wà.

**Ẹ̀wì Alohùn Yorùbá**

Oríṣiríṣi àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá ló ti fún ‘ewì’ni oríkì kan tàbí òmíràn ṣùgbọ́n èyí tí a ṣàmúlò nínú ìwádìí yìí ni Akinjógbìn (1967) tí Ọlabimtan (1980) sọ báyìí pé: “ewì ni èrò ìjìnlẹ̀ lóri ohunkóhun tí ó bá tinú ẹni wá, tó sì jẹ ẹni lọ́kàn , tí ó sì muni lára, tí a sọ tàbí tí a kọ lọ́nà tí ó múni lọ́kàn tí èdè rẹ̀ sì dùn ju bí a ti ṣe í sọ̀rọ̀ lásán lọ”(o.i.100). Ẹ̀wì tí a gbé jade lẹnu, ni ewì alohùn, èyí tí a kọ sílẹ̀ ni a pè ní ewì àpilẹ̀kọ. Ipa pàtàkì ni ewì alohùn kó nínú ìgbésí àwọn Yorùbá láyé àtijọ́ kí ìmúnisìn tó gòkè.Ó fẹ́rèd máa sí ohun tí à ṣe tí ọ̀rọ̀ ewì kì í wọ̀ . Bí à ń kí ni ni, bí à ń bú ni ni, bí a sì ń gan ni ni, ọ̀rọ̀ ewì ni Yorùbá fi ń ṣe adé orí gbogbo rẹ̀. Bí a fẹ́ mọ̀ nípa ẹ̀sìn, ìtàn-ìṣẹ̀dálẹ̀, ìwà, irísí, ìrònú, àyíká àti ìgbé-ayé àwọn baba-ńlá wa, inú ewì alohùn ni wọ́n pọ̀ sí. Ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ èrò àti ojú-àmúwayé ìràn Yorùbá lórí ohun gbogbo tó wà láyé àti àyíká wọn ló ń jẹyọ nínú ewì alohùn. Ó kọjá ẹnu jíjẹ lásán, ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tíí kọ́nilọ́gbọ́n tó sì ń pìtàn bí a ti jẹ́ fún ni ló dálé. Àwùjọ Yorùbá ló ni ewì alohùn, ogún àjọni ló jẹ́, kì í ṣe ti ọlọ́danni, ìgbà tí ètò ìmúnisìn dé ló di kí apohùn máa pe ewì kan tàbí òmíràn ní tirẹ̀! Ewì alohùn dàbí Ilé ìṣúra fún gbogbo ọmọ Yorùbá láti máa ṣàmúlò fún ìgbàdùn ẹ̀mí ara wọn, ó wà fún ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́ láti ìran kan dé ìran mìíràn. Ó wà fún ìfèròráǹṣẹ́. Àmì ìdánimọ̀ tó ń ṣe àfihàn àṣà àti ìṣẹ̀ṣe babańlá wọn ni. Gbogbo ohun tó rọ̀ mọ́ orírun àti orísun ìran àti ìtànkálẹ̀ Yorùbá ló wà nínú ewì alohùn Yorùbá. Ewì alohùn a máa jẹ́ kí àwọn ènìyàn àwùjọ ó rántí ìṣẹ̀lẹ̀ ayé àtijọ́, tòní àti tọ̀la. Ìpàrokò inú àṣà,

ìṣe, ẹ̀sìn, ìwà, ìgbàgbọ́ àti ìrònú àwọn babańlá wa lórí ohun gbogbo ló wà nínú ewì alohùn Yorùbá.

Ìsọ̀rí mẹ́ta pàtàkì ní àwọn onímọ̀ bí Ìlésanmí (1991) pín ewì alohùn Yorùbá nípa ọ̀nà ìgbéjáde wọn bí ìsàré, orin àti tí a fọ̀rọ̀ inú wọn dá wọn mọ̀. Lábẹ́ ìsàré la ti rí ewì alohùn bi: rárà, ìrèmọ́jé, ìjálá, ẹkún ìyàwó, ìyẹ̀rẹ̀-ifá,, Ṣàngó pípè, Ọya pípè, Ẹ̀ṣù pípè, òkú pípè , àti Ọ̀bàtálá pípè. Oríṣiríṣl ni orin ló wà láwùjọ Yorùbá, orin arẹmọ, orin ifẹ́, orin ogun, orin ọ̀tẹ̀, orin ajọmórogún. Orin amúṣẹ́yá, orin àpàlà, jùjù, orin sákárà, àti orin ayẹyẹ ọdún káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan ló ní eré ẹnu tirẹ̀. Ní Ondo, ni a ti rí obitun, asikò, àdàn, resọ̀, Laghalogho, àwọn Ìkálẹ̀ ló ni bírípo. Awọn Èkìti ló ni alámọ̀, àsamọ̀, orin ẹjì, orin òkòtoròjò, àpíìrì, Ùjàmẹ̀sẹ̀. Ìpínlẹ̀ Kogi ló ni orin irègún, gbògúnmọ̀, agbẹ́lẹ́gẹ́, Ogbèlè, arutà, àti obután. Ìpínlẹ̀ Kúárà ló ni orin ọpa, orin agbè, Bàlúù, dadakuada, sẹnwẹlẹ, ìyátamiwòó, orin ìyàwó, àti ẹkún ìyàwó. Ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, olele, ọsàré, ọ̀fun, orin ọ̀sun Oṣogbo, abbl. Àwọn Ọ̀yọ́ ló ni orin etíyẹrí, àwọn ìpínlẹ̀ Ògùn ló kúndùn ègè, ìgbálá, bọ̀lọ̀jọ̀, ẹ̀fẹ̀, orin gẹ̀lẹ̀dẹ́, àti apẹ́pẹ́ ní Ìjẹ̀bú. Èkó ló ni ẹ̀yọ̀. Kò sí àdúgbò kan nílẹ̀ Yorùbá tí kò ní ewì alohùn tirẹ̀ yàtọ̀ sí èyí tí a ti dárúkọ. Àwọn ewì tí a fọ̀rọ̀ inú wọn dá wọn mọ̀ ni àwíṣẹ, ọfọ̀, ayájọ́, èpè, ìwéùndeere, ìmọ́, oríkì- oríkì èèyàn, àlọ́ apamọ̀, oríkì ẹranko, igi, ẹyẹ, ohun tó lẹ́mìí àti ohun tí kò lẹ́mìí. Ìsọ̀rí yìí a máa ṣúyọ nínú gbogbo ewì alohùn Yorùbá. Àwọn ewì Yorùbá kan wà tó jẹ́ pé gbogbo ilẹ̀ Yorùbá ló kárí, bí àpẹẹrẹ: ìjálá, ẹ̀sà/iwì eégún, ẹsẹ ifá, oríkì, òwe, àlọ́ àpamọ̀ àti ọfọ̀. Àwọn kan sì wà tó jẹ́ àgbègbè kọ̀ọ̀kan ló ni wọ́n bí a ti ṣe àpẹẹrẹ rẹ̀ lókè, àwọn mìíràn sì wà tó jẹ́ pé a lè rí ní àgbègbè méjì . Bí àpẹẹrẹ, bí a ṣe ní wákà ní Ìjẹ̀bú ni a ní wákà ni Ilọrin, ohùn tí wọn fi ń gbé e jade ló yàtọ̀. Eré gẹ̀lẹ̀dẹ́ wà ni Yewa (Ẹgbádò) àti àgbègbè Ọ̀yọ́. Eré ẹnu tí a pè ní Ìgbálá ni Ẹ̀gbá ni àwọn Ọ̀yọ́ pè ní ògbérè. Yùngbà tí àwọn ayaba Aláàfin Ọ̀yọ́ máa ṣe ni àwọn Ọ̀tà Àwórì ń pè ni Igbe.

**Àbùdá Ewì Alohùn Yorùbá**

Èdè ni òpómúléró ewì alohùn, ẹnu lá fi gbé e jáde. Ohùn tí a fi gbé ewì kọ̀ọ̀kan jade yàtọ̀ síra wọn, ohùn ìjálá yàtọ̀ sí ẹ̀sà, ìyẹ̀rẹ̀-ifá yàtọ̀ sí rárà. Ètò àti ìgbékalẹ̀ ewì alohùn kọ̀ọkan yàtọ síra wọn. Oríkì ló pa gbogbo ewì alohùn pọ̀, bí apẹẹrẹ, oríkì ̦ Ṣàngó ni Ṣàngó pípè, oríkì èṣù ló wà nínú Èṣù pípè abbl. Láyé àtijọ́, ó ní àkókò ìgbéjáde, kì í ṣe gbogbo ìgbà ni èwì alohùn máa ń wáyé. Àsìkò ọdún eégún ni ẹ̀sà pípè, máa ń wáyé, ó sì lè tó ọdún mẹ́ta síra wọn. Ìgbà ọdún Àgan ní wọn ń kọrin Àgan ní ìlú Igogo Ekiti, ó lè tó ogún ọdún síra. Wọn kì í kọ ìrèmọ́jé láìsí ìkópà ọdẹ, ìdí nìyì tí wọn fi kọrin pé: ‘Ìrèmọ̀jé kì í sorin ìgbàkúgbà, orin tí à á kọ nígbà tó bá ṣòro fọ́dẹ ni’. Ìgbéjáde ewì alohùn Yorùbá máa ń fàyè gba gbogbo àwọn òǹwòran láti kópa, láti gberin tó bá yẹ, kí í ṣe apohùn nìkan ló gbé e jade, akópa lèrò ìwòran, wọn a máa jó, wọn a máa gberin pẹ̀lú apohùn. Ìmúra apohùn ṣe pàtàkì, aṣọ làgbà ni oníṣàngó ń wọ̀, ẹ̀kú laṣọ eégún, ìmúra ọdẹ asùnjálá yàtọ̀ sí àwọn ọlọ́bàtálá. Ọ̀pọ̀ ewì alohùn ló mú ìṣe dání bí ijó jíjó, orin kíkọ, títò lọ́wọ̀ọ̀wọ́, ẹ̀kú rírù, idán pípa àti ìgbẹ́gilére abbl. Nítorí ọ̀làjú òde-òní, àwọn ewì alohùn Yorùbá tí di ohun tó ń wáyé káàkiri nígbà ọdún ìbílẹ̀ tàbí ìgbà ayẹyẹ, àwọn òṣèré tíátà yálà nínú fíìmù tàbí orí ìtàgé máa ń ṣe àmúlò ewì alohùn nínú ìgbéréjáde wọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn òǹkọ̀wé ìwé ìtàn-àròsọ àti eré-onítàn máa ń ṣe àmúlò ewì alohùn nínú iṣẹ́ àtinúdá wọn, ó ti di àkọsílẹ̀ yálà nínú ìwé, nínú fọ́nrán fídíò tàbí fíìmù òde-òní.

**Ìwé Eré-onítàn Yorùbá**

Nínú èrò àti ìrònú Yorùbá láyé àtijọ́, gbogbo ohun tí a bá pè ní eré, kò túmọ̀ sí nǹkan gidi. Nǹkan ìnàjú, ìdárayá, amáratúká, ìgbádùn, ìnara àti orò-ojú lásán ni. Èrò yìí ló mú ọ̀pọ̀ ènìyàn máa fi àwọn òṣèré tíátà gbá mìníndìn láyé ìgbà kan ṣùgbọ́n kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́ lode òní. Àwọn òṣèré ti wà nípò aṣíwájú nínú ètò ọrọ̀-ajé lágbàáyé àti nílẹ̀ Nàìjíríà lode-òní. Eré-oníṣe tí a pilẹ̀ kọ sínú ìwé ni à ń pè ní “Eré-onítàn” nínú èdè ìperí Yorùbá. Ohun tí a mọ̀ sí eré-onítàn jẹ́ àtinúdá àti àròjinlẹ̀ òǹkọ̀wé kan láti ṣe àfihàn àwọn ènìyàn tí wọ́n ń ṣe

ara wọn bí ẹnikan tàbí nǹkan lọ́nà tí yóò mú kí àwọn òǹkàwé/òǹwòran ní ìrírí àti òye sí i nipa ilé ayé. Ohun tí ó bá jẹ́ àtinúdá àti àròjinlẹ̀ ti kúrò ni ohun kékeré, ohun tí ó bá dálé ìgbésí ayé ẹ̀dá àti ìrírí wọn ṣe pàtàkì, Eré onítàn ní àbùdá pàtàkì bí ìṣe, (action), ìsọ̀rọ̀gbèsì (dialogue), ibùdó eré (setting) , òṣèré/akópa (casts/actors/actresses), ìlò edè (use language), ohun èlò ìṣeré (costumes), iṣẹ̀lẹ̀ (events) àti kókó-ọ̀rọ̀ (themes) nínú. Eré lè jẹ́ ládojúdé tí ó kún ìṣẹ̀lẹ̀ ìbànújẹ́ láti ìbẹ̀rẹ̀ tití dé òpin eré, ó lè jẹ́ ẹkúndẹ̀rín tàbí ẹ̀ríndẹkún, eré sì lè jẹ́ amẹ́rìnínwá bákan náà ṣùgbọ́n tí a bá fi àkóónú rẹ̀ tàbi kókó-ọ̀rọ̀ pín wọn sí ìsọ̀rí, ìwé eré-onítàn Yorùbá ti pẹ̀ká sí oríṣiríṣi ìsọ̀rí lode-òní.

**Ìpínsísọ̀rí Ìwé Eré-onítàn Yorùbá**

Ìwé eré-onítàn Yorùbá bẹ̀rẹ̀ ní ọdún 1923 gẹ́gẹ́ bí ìwádìí ṣe fihàn pẹ̀lú ìwé eré-onítàn *Ẹni Máa kú Pàdé Ẹní Máa Pá.* O ti gbìrẹ̀gẹ̀jigẹ̀ lode-òní nítorí pé kò sí ìsọ̀rí eré-onítàn tí a rí lédè Gẹ̀ẹ́sì tí a kò lè rí lédè Yorùbá lónìí. Mólòó lọ̀kánjúà yóò mu nínú omi òkun? Díẹ̀ lára àwọn ìsọ̀rí tó gbajúmọ̀ lode-òní nìwọ̀nyí:

**Eré-onítàn afìhónú hàn** (Protest Plays): Nínú irú eré bẹ́ẹ̀, oǹkọ̀wé a máa ṣẹ̀dá àwọn òṣèré tí wọ́n ṣe tán làti kọ̀yà fún àwọn mẹ̀kúnnù tí àwọn alágbára ayé ń fìyà jẹ lọ́nà tí kò tọ́, tó sì kọjá àfaradà yálá nínú ètò ọrọ̀-ajé, ẹ̀sìn, ìṣèlú níbi tí àṣìlò agbára ti Farahan, apẹ́ẹ́rẹ irú ìwé bẹ́ẹ̀ ni *Rẹ́rẹ́ Rún* tí Ọladẹ̀jọ Òkédìjí kọ. Lọ́pọ̀ ìgbà irúfẹ́ eré náà máa ń parí sí Ládojúdé;

**Eré-onítàn adálórí ẹ̀sìn tàbí ajẹmẹ́sìn** (Religious Plays): Orí ètò ẹ̀sìn ni irúfẹ́ eré bẹ́ẹ̀ máa ń dálé, yálà ẹ̀sìn ìbílẹ̀, ẹsìn ọmọlẹ́yìn Kristi tàbí ẹ̀sìn mùsùlùmí. Lọ́pọ̀ ìgbà ìfàwùjọ ṣẹ̀fẹ̀ lórí ẹ̀sìn ló máa ń jẹ́. Bí àpẹẹrẹ: *Abẹ́ Ààbò* tí Akinwumi Ìṣọla kọ, *Ìdàámú Páàdì Mínkáílù* tí Adebayọ Fáleti kọ, *Alàgbà Jeremaya* ti Oyewale Olatunde kọ, *Ọnà Iwà Mímọ́* ti Ariyibi Adewoye kọ abbl.

**Eré-onítàn Ajẹmáwùjọ** (Social Plays/ Satiric Plays): Afàwùjọṣẹfẹ̀ ni irúfẹ́ eré bẹ́ẹ̀ máa ń jẹ́ lórí ìbáragbépọ̀ láwùjọ, ó sábà máa ń fi ìwà`ìbàjẹ́ àwùjọ gbá mììndìn yálà lórí ọ̀rọ̀ ìdílé, ìgbéyàwó ìwà jìbìtì . Apẹ́ẹrẹ irú eré bẹ́ẹ̀ *ni Nwọn Rò Pé Wèrè* Ni ti Adebayo Faleti kọ, *Aájò Ajé* tí Ọládẹ̀jọ Òkédiji kọ, *Ayé Yẹ Wọ́n Tán (Akinwumi Iṣọla)*, *Kò Ṣeégbé* tí Akinwumi Iṣọla kọ, *Oniyangi* ti Kẹmi Adágbádá kọ abbl.

**Eré-onítàn Ajẹmábo** (Feminist Plays): Irúfẹ́ eré bẹ́ẹ̀ máa ń dálé àwọn obìnrin ati àwọn ọmọdé. Òǹkọ̀wé lè jẹ́ obìnrin, ó sì lè jẹ́ ọkùnrin tí ó jẹ́ aṣègbèfábo. Obìnrin ló sábà máa ń jẹ́ olú ẹ̀dá-ìtàn. Bí ó bá jẹ́ pé ọkùnrin ló jẹ́ olú ẹ̀dá-ìtàn, gbogbo iṣẹ̀lẹ̀ inú eré máa ń ran mọ́ obìnrin lẹ́ṣẹ̀ ni látàrí àti jà fún abo ni. Apẹẹrẹ irú iwé bẹ́ẹ̀ ni: *O Ṣèyí Tán* (Adebọwale), *Afàgò Kẹ́yin Àparò* (Adejumọ), abbl.

**Eré-onítàn Ajẹmọ́ Ìṣèlú/Adáléri ìṣèlú** (Political Plays): Irúfẹ́ eré yìí máa ń dálé ìṣèlú orílẹ̀-èdè yálà ti àwọn ọba tàbi àwọn ìjọba àfìbòyànsípò. Apẹẹrẹ irúfẹ́ ìwé bẹ́ẹ̀ ni: *Ọláọ̀rẹ́ Afọ̀tẹ̀joye* (Afọlabi Ọlabimtan), *Ìṣèlú Onírèké Ògè* (Lérè Adéyẹmí),

**Eré-onítàn Ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn** (Historical Plays) Eré-onítàn yìí a máa ṣe àfihàn ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ayé àtijọ́ kí àwùjọ òde-òní lè kọ́gbọ́n lára wọn. bí àpẹẹrẹ: *Baṣọ̀run Gáà* (Adebayọ Faleti), *Lísàbi Agbòǹgbò Àkàlà* (Olu Owolabi), *Ọba Kò So* (Duro Ladipọ), *Ṣàngó* (Oladejo Okediji), *Ààrẹ Àgò Aríkúyẹrí* àti *Ọmọ Aláṭẹ Ìlẹ̀kẹ̀* (Lawuyi Ogunniran), *Ẹfúnṣetán Aniwura* (Akinwumi Iṣọla), abbl.

Nínú ìwádìí yìí, eré-onítàn ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtan tí akọlé rẹ̀ ń jẹ́ *Ọmọ Aláṭẹ Ìlẹ̀kẹ̀* tí Láwuyì Ogunniran kọ ní 1992 ni a yàn fún àgbéyẹ̀wò. Ìdí ni pé iṣẹ́ lámèyítọ́ kò ti fi bẹ́ẹ̀ pọ̀ lórí eré yìí bi ti àwọn yòókù. Kò tilẹ̀ sí àpilẹ̀kọ lórí ìṣàmúlò ewì alohùn Yorùbá nínú ìwé eré-onítàn *Ọmọ Aláṭẹ Ìlẹ̀kẹ̀* tí mo mọ̀, nítorí náà, ìwádìí yìí yóò di àlàfo ńlá tí a tọ́ka sí yìí.

**Aáyan Ọ̀mọ̀ràn lórí Ipò Ewì Alohùn nínú Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá**

Ó fẹ́rẹ̀ má sí òńkọ̀wé Yorùbá òde-òní tí kì í ṣe àmúlò ewì alohùn Yorùbá nínú ìwé wọn yálà ìtàn-àròsọ ni, eré-onítàn tàbí ewì àpilẹ̀kọ, kódà nínú eré fíìmù àgbéléwò ayé òde-òní, ìṣàmúlò ewì alohùn kó ipa pàtàkì. Púpọ̀ àwọn onímọ̀ iṣẹ́ lámèyítọ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá ló ti

jẹ́rìí sí èyí nínú ìwádìí wọn, lára àwọn iwádìí bẹ́ẹ̀ ni Bamgbose (1974, 2007) tó wo àwọn ìwé ìtàn-àròsọ D.O. Fágúnwà máràárùn àti ìjẹyọ ewì alohùn bí àló, orin, ọfọ̀, ìmẹ̀sọ ọ̀rọ̀ àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá yòókù. Ogunsina (1992 ati 2006) fi tíọ́rì soṣiọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ wo ìlò lítíréṣọ̀ alohùn nínú ìwé ìtàn-àròṣọ Fágúnwà àti àwọn òǹkọ̀wé ọmọlẹ́yìn Fágúnwà bí Ògúndélé Lagbondoko nínú *Ibú Olókun*, Lawuyi Ogúnniran nínú *Eégún Aláré* níbi tó ti fi Ẹ̀sà eégún dárà nínú ìwé tó pè ní *The Development of the Yorùbá Novel*,*1930-1975.*Ọ̀pọ̀ àwọn òǹkọ̀wé àyé àtijọ́ wọ̀nyí ló ṣe àmúlò ewì alohùn lọ́bọrọgidi láìṣe àtinúdá kan pàtó.

Olabimtan (1975) ṣe àgbéyẹ̀wò ìwé ìtàn-àròsọ Fágúnwà àti ìlò ewì alohùn bí ọfọ̀, ó sì bu ẹnu àtẹ́ lu bí Fágúnwà ṣe lo ọfọ̀ pé kò lò ó bí àwọn ọdẹ Yorùbá ṣe ń lò ó, ó ní àfẹnúpa lásán ni Fágúnwà fẹnu pa ewì alohùn Yorùbá nínú ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀. Adeyẹmi (2003) fẹnu rẹ̀ rẹ̀ jóna nínú ìwádìí rẹ̀ lórí ìhà tí Fágúnwà kọ sí àṣà àti ìṣe Yorùbá pàápàá ìlò ewì alohùn pé asọ̀tún-sòsì mábabíkan jẹ́ ni Fágúnwà. Fágúnwà ṣègbè lẹ́yìn èrò báyéṣerí àwọn amúnisìn, kò sì fọwọ́ òsì júwe ilé bàbá rẹ̀. Àwọn òǹkọ̀wé ìtàn-àròsọ Yorùbá a máa ṣe àmúlò èwì alohùn bí òwe nínú ṣíṣe àkọlé ìwé wọn bí àpẹẹrẹ: Ọládẹ̀jọ Okediji fẹ́ràn ìlò òwe gẹ́gẹ́ bí àkọlé: *Àjà ló lẹ́rù* (iró ni pẹpẹ ń pa), *Àgbàlagbà Akàn* (ó kó sí garawa), *Kárìn Ká pọ̀* (yíyẹ ní yẹni), *Bínú Tirí* (lobì ń yàn*), Ọ̀pá Àgbéléká* (tẹ̀yìn ló jù). Ìlànà lílo òwe bí akọlé yìí náà ni Adéyẹmí (2006) tẹ̀lé nínú *Àkùkọ Gàgàrà* (tó ń fọwọ́ bọ̀ṣọ́dìyẹ lẹnu, kó má baà kọ ní gbangba). Wọn a máa lo ewì alohùn nínú ahunpọ̀ ìtàn, ìfiwàwẹ̀dá, ọgbọ́n ìsọ̀tàn àti nínú kókó-ọ̀rọ̀.

Iṣẹ́ ìwádìí àwọn onímọ̀ iṣẹ́ lámèyítọ́ lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá lórí ìṣàmúlò ewì alohùn nínú ìwé eré-onítàn Yorùbá kò pọ̀ tó ti ìtàn-àròsọ. Nínú ìwádìí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ oyè ọ̀mọ̀wé ni Ogundeji ti ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn eré -oníṣe Duró Ladipọ̀ pẹ̀lú ìṣàmúlò tíọ́rì ìlò amì bí eré Dúró Ladipọ ṣe tẹ̀lé ètò ìgbéréjáde lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Ogundeji (1992) tún ṣe ìwádìí lórí ìlò ewì alohùn nínú ìwé eré-onítàn òde-òní nínú ìgbékalẹ̀ eré, ìlo èdè àti ẹwà èré. Arohunmọlaṣẹ (2001) wo iṣàmúlò orin nínú eré-onítàn *Ṣàngó* tí Okediji kọ àti *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí Iṣọ̀là kọ láti fi ètò ìṣèlú olókòwò aládàáńlá hàn wá, èyí ni bí àwọn aláṣẹ àti olówó ṣe ń rẹ́ àwọn mẹ̀kúnnù jẹ. Adejumo (2011) ló tún siṣẹ́ takuntakun lórí ìlò ewì alohùn nínú eré-onítàn Yorùbá. Ó wo ṣàkun ìbáṣepọ̀ tó ń bẹ láàárín lítíréṣọ̀ alohùn àti lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá, ó sì wí pé ọ̀rọ̀ ìbáṣepọ̀ ewì alohùn àti lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá dàbí omi àti aró, wọn kò ṣe yà. Nínú ìkòkò dúdú lítíréṣọ̀ alohùn ni lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ ti jáde àti pé adùn èdè inú ewì kúrò ní kèremí èyí tí àwọn òǹkọ̀wé àti òǹkọ̀tàn lè fojú fò, wọ́n fẹ́ràn láti máa ṣàmúlò ewi alohùn nínú ìgbékalẹ̀ iṣẹ́ wọn. Ó tẹ̀ síwájú wí pé ìṣàmúlò ewì alohùn bí òwe, ẹsẹ-ifá àti ọfọ̀ máa ń fikún adùn ìtàn, adùn èdè, àhunpọ̀ ìtàn àti kókó-ọ̀rọ̀ inú ìtàn tàbí eré. Ó ṣe ìjíròrò bí Akinwumi Iṣọla ṣe lo ẹsẹ-ifá pàápàá Ọ̀kànràn méjì láti ṣe àhunpọ̀ ìtàn rẹ̀ ninú eré-onítàn *Bellows in my Belly*. Ó wí pé 'láti inú odù Ọ̀kànràn méjì ló ti fa abala ìtàn tó rọ̀ mọ́ Ṣàngó àti Ọya yọ'. Adejumọ fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ẹsẹ-ifá ni Debọ̀ Awẹ yípadà sí ọfọ̀ nínú ìwé rẹ̀ *Ọlọ́unlúgọ*.

Akínyemi (2011) ṣe àgbéyẹ̀wò tó jinlẹ̀ lórí àwọn òṣèré òde-òní àti ipa tí èwì alohùn bí rárà, yùngbà, oríkì-orílẹ̀ ayé àtijọ́ kó nínú eré wọn yálà lédè Gẹ̀ẹ́sì tàbí lédè Yorùbá pàápàá bó ṣe jẹyọ nínú ìwé eré-onítàn *Baṣọ̀run Gáà*, tí Adebayọ Faleti kọ, *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí Akinwumi Iṣọ̀lá kọ àti àwọn yòókù. Akinyẹmi ti siṣẹ́ tó pọ̀ lórí ewì alohùn Yorùbá, tó sì jinlẹ̀ lórí ewì alohùn ààfin Aláàfin Ọ̀yọ́, bí rárà, oríkì-orílẹ̀ àti yùngbà àti ìjẹyọ rẹ̀ nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá. Ó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé kì í ṣe adùn èdè tàbí ẹwà nìkan ni ìlò ewì alohùn nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ máa ń mú bá lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá mọ̀-ọ́n-mọ̀ ń ṣàmúlò ewì alohùn kí àwọn ewì wọ̀nyí lè pẹ́ láyé, ète kí ewì alohùn má bà á parun ni, kí ìrandíran ọmọ Yorùbá lè jogún rẹ̀ nitorí tí àwọn apohùn àtijọ́ kò fi bẹ́ẹ̀ pọ̀ láyé mọ́.

## Tíọ́rì Ìṣàmúlò: Tíọ́rì Ajẹmọ́ Ìmọ̀-ìtàn-tuntun (New Historicism)

Orúkọ tíọ́rì yìí fihàn pé ọmọ ilé labọ́lá ni tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn-tuntun jẹ́ lágboolé tíọ́rì lítíréṣọ̀ lágbàáyé, èyí ni pé ìtẹ̀síwájú ló jẹ́ fún tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn (Historical theory). Nítorí

náà, tẹ̀gbọ́n tàbúrò ni tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn àti tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn-tuntun. Èròǹgbà àwọn onímọ̀ tíọ́rì méjèèjì ni láti wo ṣàkun ìbáṣepọ̀ tó wà láaarín lítíréṣọ̀ àti ìmọ̀-ìtàn. Wọ́n tako èrò àwọn onímọ̀ tíọ́rì ìfojú-ààtò-wò, pé lítíréṣọ̀ kò ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, pé àlọ́ àti àlọ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kò ju inú ìwé lọ, àti pé ìfèdèṣọnà lásán ni iṣẹ́ aláwòmọ́ lítíréṣọ̀. Tíọ́rì méjèèjì ló gbà pé ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹlẹ̀ láwùjọ nígbà kan tàbí ní sáà kan ló máa ń dìtàn, ìṣẹ̀lẹ̀ tó dìtàn àwùjọ ni òǹkọ̀wé máa ń ṣe àtinúdá rẹ̀ nínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀, nítorí náà a ò lè sọ̀rọ̀ ìtàn tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ká má rántí lítíréṣọ̀. Àbùdá méjì ló ṣe pàtàkì nínú tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn, èyí ló sì máa ń fa ìbéèrè méjì tí àwọn agbátẹrù wọn máa ń bèèrè – Kí ló ṣẹlẹ̀? Kí sì ni ìṣẹ̀lẹ̀ náà sọ fún wa nipa ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀? Nítorí náà, nínú tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn, ohun tó jẹ oníṣẹ́ lámèyítọ́ lógún ni àkójọpọ̀ onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tó di ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀, àti pé báwo ni òǹkọ̀wé ṣe hun àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà lọ́nà àtinúdá tó fi ṣe àfihàn ìtàn gidi. Báwo ló ṣe lo àhunpọ̀ ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá, ọgbọ́n ìsọ̀tàn, ibùdó eré tàbí ìtàn, èdè àti kókó-ọ̀rọ̀ láti fi ṣe àfihàn ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀? Akitiyan yìí ni oníṣẹ́ lámèyítọ́ yóò máa gbéyẹ̀wò nínú iṣẹ́ rẹ̀. Nítorí náà ṣíṣe àfiwé ìṣẹ̀lẹ̀ gidi pẹ̀lú ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ni ajolórí iṣẹ́ tí tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀ -ìtàn ń ṣe títí di nǹkan bi ọdún 1980 tí Greenblatt gbé ìwé kan jade tí ó pè ní: *Renaissance Self-fashioning*, èyí tí ó bí Tíọ́rì Ajẹmọ́ Ìmọ̀-ìtàn-tuntun (New Historicism).

Àwọn onímọ̀ tíọ́rì ajẹmọ́-ìmọ̀-ìtàn-tuntun gbàgbọ́ pé ìbáṣepọ̀ tí kò ṣe yà nipa ló wà láàárín lítíréṣọ̀ àti ìmọ̀-ìtàn. Lítíréṣọ̀ sì jẹ́ okùnso pàtàkì fún ètò àwùjọ̀. Nínú ìmọ̀ ẹ̀kọ́ ìbílẹ̀, kò sí ìpààlà láàárín ìmọ̀. Àwọn apohùn, àwọn òṣèré ìbílẹ̀ ló dàbí báǹkì ìmọ̀ ìtàn níbi tí à ń kó ìṣúra atayébáyé sí. Bí kò tilẹ̀ sí ní àkọsílẹ̀, ó wà nínú ọpọlọ àwọn apohùn. Nítorí náà ọ̀rọ̀ tí a pè ní 'ìtàn' ló jẹ́ agboòrùn fún onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ mánigbàgbé. Oríṣiríṣi ìtàn ló wà èyí dúró òté jíjẹ́ òótọ́ tàbí àìjẹ́ òótọ́, bí àpẹẹrẹ: ìtàn ìwáṣẹ̀, ìtàn akọni kàyééfì, ìtàn-orírun, ìtàn àlọ́-onítàn, ìtàn-àròsọ, ìtànyítàn, ìtàn yẹmíwò. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìtàn so mọ́ àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí, síbẹ̀ gbogbo wọn kọ́ ni a lè pè ní ìtàn gidi tó jẹ́ òtítọ́ ìtàn (history), bí ìtàn tilẹ̀ wà nínú àlọ́-onítàn, kì í ṣe ìtàn tòótọ́, ṣùgbọ́n àwọn arọ́tàn/òpìtàn a máa lo ìtàn-ìwáṣẹ̀ àti ìtàn akọni láti fìdí ìtàn gidi balẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, nínú ìtàn ìwáṣẹ̀, Ṣàngó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn òrìṣà tí ó ní olùsìn.

Nínú ìtàn gidi,ènìyàn ni Ṣàngó tí ó jẹ Aláàfin kẹ́rin ní ìlú Ọ̀yọ́, orúkọ rẹ̀ ni Ìtíolú Babayẹmí. Nítorí pé ìṣesí, ìwà àti ìse rẹ̀ jọ ti òrìṣà Ṣàngó, ó di òrìṣà lẹ́yìn ikú rẹ̀, ó sì di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ. Nílẹ̀ Yorùbá, kò sí ìpààlà láàárín ìtàn gidi àti ìtàn-ìwáṣẹ̀ ìdí nìyí tí Bohrer àti Wenger (1976) fi sọ pé: *Ṣangó is also important because of his human history as the Aláàfin of Ọyọ. He is not a myth like others, he is both very human and very godly* (p.12) (Ṣàngó ṣe pàtàkì nítorí ìjénìyàn rẹ̀ nínú ìtàn bí Aláàfin Ọ̀yọ́. Kì í ṣe ẹni ìtàn ìgba ìwáṣẹ̀ nìkan bí ti àwọn yòókù, ó jẹ́ ènìyàn, ó tún jẹ́ òrìṣà). Nínú ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ Ifẹ̀, a rí Moremi gẹ́gẹ́ bí ènìyàn tó gba Ilé-ìfẹ̀ sílẹ̀ lọ́wọ́ ọ̀ta, ìtàn gidi yìí ló di ìtàn-ìwáṣẹ̀. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé, kò fi bẹ́ẹ̀ sí ìpààlà láàárín ìtàn gidi àti ìtàn-ìwáṣẹ̀. Ìtàn ìgbà ìwáṣẹ̀ àti ìtàn akọni kì í ṣe irọ́ lójú àwọn Yorùbá.

Nínú tíọ́rì ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn-tuntun, ìmọ̀-ìtàn kì í ṣe òótọ́ pọ́ńbélé, ó dúró lórí arọ́tàn tàbí òpìtàn. Ipò agbára tó bá wà máa ń kópa nínú kíka ìtàn bẹ́ẹ̀ sí òótọ́ tàbí iró. Ìbéèrè méfà ni àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí sábà máa ń bèèrè lórí ìwé eré-onítàn tàbí ìtàn-àròsọ adálórí ìtàn gidi. Àwọn ìbéèrè náà nìwọ̀nyí:

i. Kí ló ṣẹlẹ̀?
ii. Kí ni ìṣẹ̀lẹ̀ náà sọ fún wa nipa ìtàn?
iii. Báwo ni a ṣe fún ìṣẹ̀lẹ̀ náà ní itumọ̀?
iv. Irúfẹ́ ìlò èdè wo ni òǹkọ̀wé lò, àwọn ẹ̀dá ìtàn/òṣèré àti ìṣẹ̀lẹ̀ wo ló ṣe àfihàn ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń lọ lọ́wọ́ nígbà ayé òǹkọ̀wé?
v. Báwo ni ìfúnnitumọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àti àfihàn ìtàn ṣe bá àṣà àwùjọ òǹkọ̀wé mu?
vi. Báwo ni eré/ìtàn náà ṣe ṣe àfihàn tàbí àtakò àwọn aláṣẹ ìgbà náà sí?
vii. Báwo ni iṣẹ́ náà ṣe ṣe àfihàn àwọn tí ẹnu wọn ò tókè/ mẹ̀kúnnù láwùjọ sí ?

Àwọn onímọ̀ tíọ́rì yìí gbàgbọ́ pé ìmọ̀ ìtàn kì í ṣe àtọ̀jọ ìṣẹ̀lẹ̀ ní síṣẹ̀-n-tẹ̀lé, ṣùgbọ́n ó jẹ́ àkànpọ̀ àpèjúwe ìbáyému ènìyàn àti èrò inú ẹnikan lórí ìṣẹ̀lẹ̀. Èyí ni pé ìfúnnitumọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tó di ìtàn dúró lórí ipò ẹni tó ṣe àkọ́ọ́lẹ̀ rẹ̀ àti ìhà tí ẹni náà kọ sí i. Ohun mìíràn tó ń kópa lórí ìfúnnitumọ̀ ìtàn ni àyíká òǹkọ̀wé, ìgbàgbọ́, èrò báyéṣerí rẹ̀ àti ìgbà rẹ̀. Kí ló ṣelẹ̀ nínú eré *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀*? Báwo ló ṣe hun ìṣẹ̀lẹ̀ pọ̀ tó fi gbé ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ gidi jade, èròjà ewì alohùn wo ló lò láti mú wa rí ìṣẹ̀lẹ̀ ayé àtijọ́? Àwọn ìbéèrè wọ̀nyí àti àwọn mìíràn lá gbéyẹ̀wò nínú àpilẹ̀kọ yìí.̩

**Ìtàn Ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá tí òǹkọ̀wé ṣe afihàn rẹ̀ nínú Eré *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* ní ṣókí**

Alàgbà Láwuyì Ògúnniran jẹ́ ọ̀kan lára àwọn òǹkọ̀wé pàtàkì láwùjọ Yorùbá, ọmọ bíbí ìlú Ìbàdàn ni, akéwì ni, òpìtàn sì ni pẹ̀lẹ́. Ó fi ọgbọ́n àtinúdá tó kira sọ ìṣẹ̀lẹ̀ kan pàtó nínú ìmọ̀ -ìtàn ilẹ̀ Yorùbá di eré pàtàkì, kí a tó ṣe ìjíròrò lórí ìṣàmúlò ewì alohùn nínú eré náà, ó wúlò láti lọ sínú ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ tí ó lò ní ṣókí. Ṣáájú kí Aláàfin Abíọ́dún tó dórí oyè ni oríṣiríṣi ìwà ìkà ti gbilégbiko ní ilẹ̀ Yorùbá. Èyí tó burú jù ninú ìwà ìkà náà ni jíjí ènìyàn gbé àti òwò ẹrú. Awọn Yorùbá ń ta ara wọn lẹ́rú nítorí owó, wọ́n sì ń jara wọn lógun, wọ́n ń ta ẹrú, wọ́n sì ń kó ẹrù ara wọn. Aláàfin Abíọ́dún Adegolu ló paná ìwà ìkà yìí mọ́lẹ̀ nígbà tó gorí oyè, ṣùgbọ̀n ní kété tó wàjà ni wàhálà tún bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Nígbà ìṣèjọba Aláàfin Aólẹ̀ tó jẹ lẹ́yìn Abíọ́dún, ìlú gbẹ̀kan, ó kan bí ìbó, ó korò jú dapa lọ. Àsìkò rẹ̀ ni iná ìtẹ̀síwájú ilẹ̀ Yorùbá jó àjórẹ̀yìn kí ó tó wà ṣubú yakata nígbà Aláàfin kárùn-ún tó jẹ lẹ́yìn Aláàfin Abíọ́dún. Nínú ìtàn Yorùbá láyé àtijọ́, ọjà pàtàkì ni ọjà Apòmù. Ọ̀pọ̀ ìlú Yorùbá ló máa ń wá ná ọjà náà. Lára àwọn ìlụ́ bẹ́ẹ̀ ni Ọ̀yọ́, Ifẹ̀, Òwu, àti Ìjẹ̀bú. Ọ̀kan pàtàkì nínú ọjà tó tà jù ẹrú, èyí mú kí òwò ẹrú ó pọ̀ sí, ìjínigbé àti ìkógunjani pọ̀ káàkiri abala ìtàn yìí ni òǹkọ̀wé fẹ̀ lójú pẹ̀lú ìṣàmúlò ewì alohun Yorùbá bí òwe, oríkì, àwíṣẹ, ayájọ́, ọfọ̀, ìwúre àti orin tó sọ di eré alárinrin àkàgbádùn.

**Ìṣàmúlò Òwe nínú *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀***

Ọ̀kan lára àwọn ewì alohùn tí àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá kúndùn jù nínú ṣíṣe àhunpọ̀ ìtàn àti ìgbékalẹ̀ eré ni ìlò òwe, kò fi bẹ́ẹ̀ sí òǹkọ̀wé Yorùbá tí kì í lo òwe nínú iṣẹ́ ọnà wọn, ṣùgbọ́n ti Alàgbà Láwuyì Ògúnniran yàtọ̀ nítorí tọlọ́tọ̀ ní tòun ọ̀tọ̀. Àwọn gbankọgbì òwe ló fi hun eré *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* pọ̀. Àkọlé eré gan an, òwe ni! Òwe jẹ́ ọ̀rọ̀ ọgbọ́n tí àwọn ọ̀mọ̀ràn ilẹ̀ Yorùbá máa ń lò láti fi ṣe àlàyé tàbí láti fi gba ènìyàn ní ìyànjú tàbí láti fi kìlọ̀ ìwà tí kò dára tó. Òwe lẹṣin ọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ lẹṣin òwe, bí ọ̀rọ̀ bá sọnù, òwe la fi ń wa!

Ní ìbẹ̀rẹ̀ eré àwọn ajínigbé ń sọṣẹ́ wọ́n ń ta ènìyàn lẹ́rú lọ́jà Apòmù. Òyìnbó tilẹ̀ sọ pé baba àti ìyá lòun fẹ́ rà, òun kò fẹ́ ọmọ, ó sì pàṣẹ kí wọn yọmọ nù lẹ́yìn abiyamọ. Àwọn Ifẹ̀ ló ń jí Ọ̀yọ gbé, Ìjẹ̀bú ló ń ra ẹrú tí wọ́n sì ń tà wọ́n lọ́jà Apòmù. Bí àwọn ajinigbé ṣe ń jí àwọn ará Ọ̀yọ́ gbé, kò dùn mọ́ Aláàfin nínú, Olówu náà faramọ́ Aláàfin, ó wí pè: 'Ní tèmi Olówu, n kò ṣòwò ẹrú mọ́. N kò sì sọ̀tẹ̀ sí Aláàfin. Omi ló ni kete, kete lo lomi lọ̀rọ̀ Òwu àti Aláàfin jẹ́' (o.i.7). Ó sì fi òwe sọ ìdí rẹ̀ tó fi ti Aláàfin lẹ́yìn láti dáwọ́ òwò ẹrú dúró, ó wí pé: "Láti ayé Aláàfin Ṣàngó, Arábánbí ọkọ Ọya, Òwu àt'Ọ̀yọ́ kò gbọ́wọ́ ìjà síra wọn. Akọni làwa méjèèjì, Bẹ́ẹ̀ ni, bá a bá mú ìṣàkọ̀tún, tá a mú ìṣàkòsì, ìṣàkuṣà ló kù (o.i. 7). Ohun tí Akọgun Òwu ń wí ni pé, alágbára ni Òwu àti Ọ̀yọ́, àwọn ni 'ìṣàkọ̀tún'àti ìṣàkòsì', àwọn orílẹ̀ yòókù kò lágbára bí ti wọn, àwọn ni' ìṣàkuṣà' . Bí eré ṣ ń tẹ̀ síwájú, Olówu pàṣẹ fún Akọgun rẹ̀ láti kìlọ̀ fún àwọn ìlú abẹ́ Ifẹ̀ láti dáwọ́ ìjnigbé dúró bí bẹ́ẹ̀ kọ́ wọn yóò gbogun tì wọ́n., Olówu parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ báyìí pé:

> Ẹ̀yin ènìyàn mi. Ẹ sọ f'Áláàfin bí mo ṣe pàṣẹ f'Akọgun mi nǹì, Báwọn
> Ajnigbé bá kọ ìkìlọ̀ Olówu náà, Aláàfin yóò gbúròó gbọ́ lóde Ọ̀yọ́ pé lálà lù, gọngọ sọ.
> ṣùgbọ́n o, Ìwọ Oníkòyí ni mò ń bá wí! Odídẹrẹ́, ẹyẹ ìlú òkun, Àlùkò, ẹyẹ ìlú ọ̀sà,
> bó bá jojú gbé, kó má johùn gbé o. Bójú bá yẹjú, kóhùn má yẹ'hun (o.i. 9)

Àwọn ajínigbé kò dẹ́kun, nítórí náà Akọgun Òwu kógun ja Ifẹ̀ àti àwọn ìlú abẹ́ rẹ̀. Olúwòó gba Ifẹ̀ láyè lórí ilẹ̀ wọn láti bá Òwu jagun, Olówu rán Akọgun rẹ̀ láti kìlọ̀ fún Olúwòó, òwe ló fi pàrokò ránṣẹ́, ó wí pé:

Bá ti ń yọ́ só, là ń yọ́ gbọ́.
Iná tá a dá nílé, gọ̀gọ̀ rẹ̀ ń yọ lóde;
Má-sọ-ọ́ lóògùn má-gbọ́-ọ́. Má-ṣe-é lóògùn má-mọ̀.
Olówu ni, gbogbo ìwà t'Ólúwòó hù lórí ọ̀rọ̀ yìí lòun mọ̀ pátápátá
. Ó ní òun kàn fi gbígbọ́ ṣalàì gbọ́, tóun fimímọ̀ ṣalàì mọ̀ ni.

Ṣùgbọ́n òun kò fẹ́ bá a jà nítorí pé aládùúgbó àtọmọ ìyá kan náà làwọn (o.i 15)

Bí eré ti ń tẹ̀ síwájú, àgbáríjọ ogun Ifẹ̀, Ìjẹ̀bú àti àwọn ìlú yòókù dìde sí Òwu wọ́n pinnu láti pa Òwu run. Ọ̀rọ̀ ogun ti fẹ́ máa sú àwọn Ọ̀yọ́, àwọn obìnrin Ọ̀yọ́ dìde láti fìhónú hàn sí Aláàfin, wọn kò sọ̀rọ̀ sákálá sí Aláàfin, òwe ló pa láti fi pàrọwà fún àwọn aláṣẹ ìlú. Olórí Obìnrin wí pé:

Bí aré, bí aré, ọwọ́ pálábá ń ségi nínú igbó!

Ẹja ń tán nínú omi!

Kọ̀ǹkọ̀ ń gbàwọ̀!

Mo mọ̀bàrà, mo mọ̀fún kan

Kò sí mọ́ báyìí o,

Ẹ ẹ̀ bá'ṣìn-ín mawo,

Ẹè bá kòrò mulẹ̀,

Ẹ ní bábẹ́rẹ́ yín bá bọ́ sódò

Ẹ ó yọ ọ́!

Ẹ pe Olúgbọ́n, Ẹ pe Arẹ̀sà, Ẹ pe Oníkòyí

Ẹ pe gbogbo ọba tó ti bínú lọ….(o.i 40)

Ohun tí olórí obìnrin ń wí nínú òwe yìí ni pé ìlú ti tú mọ́ Aláàfin Aólẹ̀ lórí tán, kò sì fiyèsi ó sì ń pàrọwà kí Aláàfin ó bẹ àwọn ìlú àmọ̀nà gbogbo kí ogun ó sì rọlẹ̀, nítorí pé ìlú ti gbẹ̀kan jù. Ìdáhùn Aláàfin sí àrọwà àwọn obìnrin fihàn pé ọ̀rọ̀ náà ti yíwọ́, Ọba fèsì pé

Ìlẹ̀kẹ̀ já sínú, má já síta:

Ìlẹ̀kẹ̀ já síta, má já sínú,

Ibìkan sá ni ìlẹ̀kẹ̀ yóò já sí?

Wọ́n ní ilé ayé kò ṣe gbé, Ọ̀run kò sì ṣe é lọ

Ibìkan náà ni yóò já sí (o.i 37)

Àgbàakin ló sọ ìdí rẹ̀ tí gbogbo rẹ̀ fi dojúrú mọ́ wọn lọ́wọ́ èyí sì ni ìsọ̀tẹ̀ sí Aláàfin tí àwọn ìlú amọ̀nà bí Ìdọ̀ọ̀mì, Tápà, Ìbàrùbá, Pópó, Kétu, Ẹgbá tí wọn kò sìnrú mọ́. Bí ogun ṣe ń gbóná mọ́ Òwu, tí àgbárijọ ogun Ifẹ̀, Ìjẹ̀bú àti Ẹ̀gbá ń le sí i, Olówu rán Akọgun Òwu sí

Aláàfin Ọ̀yọ́ fún ìrànlọ́wọ́ gẹ́gẹ́ bí àdéhùn tí wọ́n ti jọ ṣe tẹ́lẹ̀, òwe ni Aláàfin Ọ̀yọ́ fi pàrokò ránṣẹ́ sí Olówu pé àdéhùn ti yẹ̀:

Aláàfin: Ẹ fetí lélẹ̀ kí ẹ gbọ́ iṣẹ́ tí n ó rán yín s'Ólówu: Ẹ wí fún un pé:

Àrùn tí ń ṣogóji ló ń ṣọ̀ọ́dúnrún
Ohun tó ń s'Abọ́yadé gbogbo ọlọ́ya ló ń ṣe
Ẹ tún sọ fún un pé
Ọ̀jọ̀jọ̀ ń ṣògún, ara ògún ò le
Ẹ tún sọ fún un pé
Odídẹrẹ́ ẹyẹ ìlú òkun
Àlùkòréré, ẹyẹ ọ̀sà
Kò fẹ́ jojú gbé kó tún johùn gbé
Ṣùgbọ́n kẹ́kẹ́ ti pa mátíòro wọn lẹ́nu
Kí ẹ sọ f'Ólówu pàtó pé
Ilé Ọba ń jó, ilé Ọba ń jò
Ọba wà lórí kòbà -kòle
Bíná bá sì jóni tó jómọ ẹni
Tara ẹni là ó yanjú (o.i. 42)

Oríṣi òwe mẹ́fà ni Aláàfin fi pàrokò sí Olówu, èyí ni a pè ní Àsínpọ̀ òwe/Àjànpọ̀ òwe. Nínú ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá, òrìṣà pàtàkì ni Ògún àti Ọya. Ògún ni Ọsìn Mọlẹ̀ tó jẹ́ alágbára. Ọya náà jẹ́ akọni òrìṣà, ṣùgbọ́n Ògún ń ṣòjòjò báyìí kò lágbára àti ranni lọ́wọ́. Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ ni òwe yìí. Aláàfin ló dúró bí Ògún ṣùgbọ́n kò lágbára báyìí nítorí òjòjò! Kò sì lè ran Olówu lọ́wọ́ nínú ogun tó délẹ̀. Ó lo àwọn àsínpọ̀ òwe wọ̀nyí láti sọ ìdí rẹ̀ tí àdéhùn fi yẹ̀ tí kò fi lè ran Olówu lọ́wọ́ nínú ogun náà. Kò sí agbára mọ́, ògun náà kàn wọ́n gbọ̀ngbọ̀n, kò sí agbára fún òun náà láti ran ẹlòmíràn lọ́wọ́. Àgbáríjọ ogun Ifẹ̀, Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú àti àwọn ìlú yòókù borí àwọn Òwu wọ́n sì pa Òwu run!

Kókó ọ̀rọ̀ tó jẹ òǹkọ̀wé lógún jùlọ ni ìṣọ̀kan àti ìmúdúróYorùbá lẹ́yìn onírúurú ogun tó ja ilẹ̀ Yorùbá, onírúurú ọ̀nà ló gbà láti fi ẹsẹ ìṣọ̀kan yìí múlẹ̀ pé ó ti wà tẹ́lẹ̀ rí, orí èyí ni àkọlé eré náà dúró lé, tó fi sọ àwọn Yorùbá ní Ọmọ Aláte̩ Ìlẹ̀kẹ̀. Ẹ̀yìnlàárò ló fi ẹsẹ ọ̀rọ̀ náà múlẹ̀ nígbà tó ń parí ìjà láàárin àwọn lọ́balọ́ba Yorùbá, ìjìnlẹ̀ òwe ló lò, ó wí pé:

Ẹ̀yin Ọmọ Aláte̩ Ìlẹ̀kẹ̀
Ẹ̀yin ọmọ aláte̩ àkún
Ẹ̀yin ọmọ tó bọ́lánlé
Ẹ̀yin ọmọ ẹni a bíire
Ilé ọlá tẹ ẹ wó yìí
Ṣe ẹ fi tẹ́yìn Oòduà ṣe ni?

Àfàìmọ̀ kí tèfètèfè má yọwó ọjà

Àfàìmọ̀ kí sákeṣàke má dádìí

Àfàìmọ̀ kọ́mọ Aláṭẹ ìlẹ̀kẹ̀

Kó má dọmọ ọ̀rúnlá (o.i. 86-87)

Òwe yìí ń tọ́ka sí ipò ọlá, ipò ọrọ̀ àti iyì tí a mọ̀ mọ́ Yorùbá láààrọ̀ ọjọ́. Ìlẹ̀kẹ̀ ni wọ́n fi ń ṣe adé orí ọba. Àkún àti àwọn ìlẹ̀kẹ̀ olówó iyebíye tọ́ba fi ń sọ́rùn, tó fi ń sọ́wọ́, àwọn bi iyùn àti sẹ̀gi àwọn ohun àmúṣọ̀ṣọ́, àmúṣoge àti àmúṣẹ̀yẹ fún àwọn àgbà ìjòyè lọ́kùnrin àti lóbìnrin títí kan àwọn ọmọge tó ń lọ ilé ọkọ, kò sẹ̀yìn ìlẹ̀kẹ̀. Nítorí náà ìran ọlọ́lá, ìran àwọn ọmọ aládé àti olówó ni ìran Yorùbá ṣùgbọ́n:

Ogun àjààṣíwọ́ lẹ fi fọ́lé Òwu

Ogun àjààwẹ̀yìn lẹ fi fọ́lẹ̀ Oòduà

Ọta ń dún firifiri

Òfà ń kù fìrìfìrì

Òkúdìẹ kò mojú ẹni tí ń tu ú!

Hàáàà! (o.i 86)

Òǹkọ̀wé kò fi ẹnu lásán sọ kókó ọ̀rọ̀ yìí, ó lo ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré láti mú kí a rí ogun tí wọ́n gbé tira wọn, Ẹ̀yìnlààrò sọ báyìí pé:

Ẹ ẹ̀ mọ̀ pé, emírín kì í jẹni ká rèé kìbọn

A kì í fàkàtàǹpò pàmúkùrù

Bémírín bá jẹni, ta rè é kìbon

Ikú lè pemínrín, ó lè pẹni emírin ń jẹ

Bá sì tàkàtàǹpò nítorí àmúkùrù, ikú lè alákàtàǹpò,

´ ó lè pàmúkùrù (o.i. 86)

Ayọlò yìí lóòrìn, ó wúwo, ó sì yàwòrán ketekete pé Yorùbá ló ń fọwọ́ ara wọn ṣera wọn nípa bíbá ara wọn jagun, ó bá gbogbo àwọn ọba Yorùbá wí ó rọ̀ wọ́n láti máa fìfẹ́ bára wọn ṣe kí ìran wọn má bà á 'dọmọ aláṭẹ ọ̀rúnlá' láwùjọ ilẹ̀ Nàìjíríà.

**Ìṣàmúlò Oríkì nínú *Ọmọ Aláṭẹ Ìlẹ̀kẹ̀***

Ewì alohùn mìíràn tí òǹkọ̀wé yìí tún ṣe àmúlò rẹ̀ dọ́ba ni oríkì. Oríkì jẹ́ pàtàkì nínú ewì alohùn Yorùbá, àwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn Yorùbá sì mọ̀ bẹ́ẹ̀, nítorí náà, wọn a máa ṣe àmúlò oríkì fún ète ìfìwàwẹ̀dá, láti fi àwọn òṣèrè han àwọn òǹkàwé àti láti mú adùn wọnú eré wọn. Gẹ́gẹ́ bi Ọlajubu (1978) ti wí, ara orúkọ ni oríkì wà. Kíki oríkì ẹni máa ń mú kí orí àwọn èrò ìwòran àti ẹni tí à ń kì wú, ó sì máa ń mú kí ara wọn yá lati fún apohùn lówó. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé bí a bá ki òrìṣà lákìdélẹ̀, inú rẹ̀ á dùn láti gbọ́ ẹ̀bẹ̀ ẹni. Ẹ̀yí ló fà á tí àwọn apohùn ìbílẹ̀ máa fi ń tẹnu mọ́ oríkì ju ọ̀rọ̀ gbogbo tó kù lọ.

Lọ́pọ̀ ìgbà, a lè mọ ìríṣí, ìhùwàsí àti ìṣesí òṣèrè àbí ẹ̀dá-ìtàn kọ̀ọ̀kan nípa oríkì tí òǹkọ̀wé fún wọn. Orúkọ a máa roni. Nínú eré yìí, òǹkọ̀wé lo oríkì bọ̀rọ̀kìnní láti fún àwọn ẹ̀dá ìtàn kan lórúkọ, a tún rí ìsàmúlò oríkì òrìsà àti oríkì-orílẹ̀. Ìsọ̀rí mẹ́ta ni a lè pín àwọn

òṣèré`inú eré yìí sí, Ìsọ̀rí àkọ́kọ́ ni àwọn ọba àti ìjòyè wọn, àwọn jagunjagun àti àwọn ajínigbé ni ìsọ̀rí kejì, ìsọ̀rí kẹ́ta ni àwọn ará ìlú, lọ́kùnrin lóbìnrin, awọn mẹ̀kúnnù tí a jígbé. Orúkọ àdàpè tàbí oríkì ìnagijẹ ni òǹkọ̀wé lò fún àwọn ọba àti babańlá wọn, bí àpẹẹrẹ: Ẹ̀yìnlàárò ló dúrú fún orúkọ Oòduà tó jẹ́ babańlá ìran Yorùbá èyí tó túmọ̀ sí pé ẹ̀yìn ni a gbọdọ rò wò kí a tó hùwà tàbí gbé ìgbèsẹ̀ tó lè pa ọmọnìkejì lára. Ẹ̀yìnlàárò ni òǹkọ̀wé lò láti yanjú èdè àìyédè tó wà láàárín àwọn ọba Yorùbá, òun ló sì fún àwọn ọba yòókù lóríkì tó bá ìṣe àti ìwà wọn mu. Àwọn orúkọ tó fi ìrísí ohun kan tàbí ẹ̀dá kan hàn ni à ń pè ni oríkì rẹ̀.

Aláàfin Ọ̀yọ́ ló pè ní Ọlọ́gbọ́n-ilé-Ọ̀yọ́

Ọ̀ọ̀ni Ifẹ̀-----Ọ̀mọ̀ràn-ilé-Ifẹ̀

Olówu ------- Àyàkoko-ǹ-nàkí

Aláke Ẹ̀gbá -----Májẹ̀ẹ́kóbàjẹ́-ọmọ-Ẹ̀gbá-láké

Awùjalè Ìjẹ̀bú -----Olówólayémọ̀ ọmọ Awùjalẹ̀

Èwí Adó --------- Adégbáremú ọmọ Ewí Adó

Ìwà àti ìṣe kálukú ló fi fún wọn ní oríkì inagijẹ wọ̀nyí. Ẹ̀yìnlàárò ló fúnra rẹ̀ fọ́ ìtumọ̀ oríkì kọ̀ọ̀kan sí wẹ́wẹ́ báyìí pé:

1. Ọlọ́gbọ́n-ilé-Ọ̀yọ́ lọ́gbọ́n nínú ṣùgbọ́n kò lè fi solé Ọ̀yọ́ ró, Ó mú
   ọwọ́ líle ń darí àwọn tó wà lábẹ́ rẹ̀ (o.i 74)
2. Májẹ̀ẹ́óbàjẹ́ ọmọ òde Ẹ̀gbá l'Aké ń ṣeku ṣẹyẹ, Ẹ̀gbá Ìkijà ń ṣe tÒ'wu
   ÌsàǹsáẸ̀gbá ń ṣe tìjẹ̀bú àti Ifẹ̀ nínú ogun Òwu (o.i. 75)
3. Olówólayémọ̀ ọmọ Awùjalè Ìjẹ̀bú ló ń ta ọta àtètù fáwọn
   Ọmọ bàba rẹ kí wọn ó máa fi jara wọn lógun kí o bà á lè
   rẹ́rú tà f'Èèbó! Nítorí owó! (o.i. 75)
4. Ìwọ Àyàkoko-ǹ-nàkí ọmọ Ẹ̀gbẹ̀jí nílé Òwu, àwíìfẹ́,
   Àfọ̀ọ̀gbà, àwíìyannu, agídípáálí àti àìro-ẹ̀yìn-wò ló fi ń ṣọlá
   Kowéè Òwu kì í ké ẹ̀rọ̀-ṣẹ̀ṣẹ̀ àfi èle koko! (o.i. 75)

Ẹ̀yìnlàárò bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà ìkà, ìfẹ́ owó ju ẹ̀mí èniyàn lọ, agídí páálí, ẹ̀mí ìjà àti àìṣọ̀kan àwọn ọmọ aládé tí wọn kò mọyì ara wọn, ó kì wọ́n báyìí pé:

Ẹ̀yin Ọmọ Alátẹ Ìlẹ̀kẹ̀

Ẹ̀yin ọmọ alátẹ àkún

Ẹ̀yin ọmọ tó bọ́lańlé

Ẹ̀yin ọmọ ẹni a bíire

Ẹ̀yin ọmọ Oòduà (o.i. 87)

Nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, àpèmọ́ ìbí ló wà nínú oríkì iran Yorùbá: 'Ọmọ Alátẹ ìlẹ̀kẹ̀', 'ọmọ alátẹ àkún' a ò rí ìríṣí wọn tàbí àpèjúwe wọn ṣùgbọ́n nítorí ìwà burúkú àwọn aṣíwájú ìran yìí ni òǹkọ̀wé ṣe kọminú sí oríkì wọn pé:

Àfàìmọ̀ kọ́mọ Alátẹ ìlẹ̀kẹ̀

Kó má dọmọ Alátẹ ọ̀rúnlá

Ọdúnnìí, oo ku mérin

Ẹ̀ẹ̀mínìn, o o ku mẹ́fọ̀n,

Ọdún mẹ́ta òní

Oo ku mélìírí

Ọlá ń rewájú ni

Àbọ́lá ń rẹ̀yìn-ìn-ìn? (o.i. 87)

'Kó má dọmọ alátẹ òrúnlá' nínú àyọlò yìí túmọ̀ sí kí àwọn ọmọ ọlọ́lá, aṣíwájú àti olórí má bà´a dẹni tó wà ní ipò ẹ̀yìn, ipò òṣì, àìní, ẹ̀gàn àti ẹni àbùkù nítorí ìwà burúkú wọn.

Yàtọ̀ sí oríkì-orílẹ̀ ìran Yorùbá, òǹkọ̀wé ṣe àmúlò oríkì Oòduà fúnra rẹ̀, àwòrò Ifẹ̀ ló sì fi oríkì náà sí lẹ́nu, Kíki àwọn babańlá nígbà ìṣòro jẹ́ ìṣẹ̀ṣe pàtàkì nílẹ̀ Yorùbá kí ẹ̀sìn àjèjì tó wọ ilẹ̀ Yorùbá. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé tí ọ̀rọ̀ bá rújú baba ẹni ni ìṣẹ̀ṣe ẹni, òun náà ni a lè ké sí fún ìrànlọ́wọ́. Wọ́n a rúbọ, wọn a ṣètùtù. Nínú eré yìí, Abọrẹ̀ Ifẹ̀ pe Oòduà, ó sì ki oríkì náà, kí Oòduà wá bá Ifẹ̀ pa Òwu run tọmọtaya nítorí ọwọ́ Ifẹ̀ kò ran Òwu. Oòduà kò fẹ́ràn ìwà ibi rárá, ẹbọ Ifẹ̀ kò gbà lọ́jọ́ náà.  Abọrẹ̀ Ifẹ̀ ki Oòduà báyìí pé:

Oòduà mo júbà rẹ o!
Ẹ̀rù jẹ̀jẹ̀ àdúgbò
Atúniṣe-má-bani-jẹ́
A-girigiri Ọ̀gán
Ò jí láàárọ̀ bẹ́ rìrì
Ìwọ Oòduà!
O bá iná jà, ó dáná
O bá oòrùn jà, o dá oòrùn
O bá Dagba jà lẹ́sẹ̀ Ọya, o dá Dagba
O bá ààkàrà lójú omi, o tẹ̀ẹ́ rì (o.i. 25)

Àbùdá àpèjúwe àti ìtọ́kasí ni a rí nínú oríkì Oòduà, pé ẹni ẹ̀rù ni, alágbára tí kì í ṣe ìkà ni ṣùgbọ́n kò sẹ́ni tó lè borí rẹ̀ nínú ìjà.  Nígbà tó dàbí pé Oòduà kò gbọ́ ẹ̀bẹ̀, Abọrẹ̀ tún mú oríkì Ọ̀rànmíyàn, ó tún fi ẹjọ́ Òwu sùn, ó ń ki báyìí pé:

Ọ̀rànmíyàn, máa gbọ́ o!
Ọ̀dẹ̀dẹ̀ Eléǹpe Ìwágún
Akin ọ̀tún, Akin òṣì
Akin nílé, Akin lógun
Ó kógun sápò yànmùyànmù…
Bó bá dámọ lápá, a dámọ nítan
Ìwọ lọkùnrin pupa Ìrámọ
Onílé ojú pópó
Atófaratì-má jayà lolo
Kó sin Ifẹ̀ lọ, kó o sin Ifẹ̀ bọ̀! (o.i.26)

Nígbà tí ìjà gbóná girigiri tán, àwọn ọba bẹrẹ̀ sí bọ àwọn òrìṣà ìlẹ̀ Yorùbá láti wá ràn wọ́n lọ́wọ́ láti borí ogun tí wọ́n gbé tira wọn. Awùjalẹ̀ Ìjẹ̀bú ló kọ́kọ́ fẹjọ́ Òwu sun Ògún, wọ́n ń ki Ògún báyìí pé:

Ìwọ Ògún Lákáayé,
Onílékángunkàngun òde-ọ̀run,
Àwàlàwúlú epo
Àwàlàwúlú ẹ̀jẹ̀
Àwàlàwúlú òòṣà
Tí í jẹ'gba ekòló má bì
Jẹ́ kí ṣìṣe ṣìṣe ó máa bá Òwu.. (o.i. 22)

Ní Ifẹ̀ bákan náà, Ọọni ń ki Ògún léraléra kí orí ògún lè wú kí ó bá wọn bá Òwu jà, ó ń ki ògún báyìí pé:

Ògún ǹlẹ́ o, Lákáayé Ọṣìnmọlẹ̀
Gbáú bi igi dá! Wọ̀ bí oòrùn wọ̀
Ògún eléwèlè ọkùnrin;
Akọ ẹran tíí forí jà
Tí fìrù jà (o.i. 26)

Lẹ́yìn tí àgbaríjọ ogun Ifẹ̀, Ègbá àti Ìjẹ̀bú ti tú Òwu, tí Olówu Akínjọbí ti filẹ̀ bora bí aṣọ, àwọn Fulani ṣígun sí Ọ̀yọ́, Abọrẹ̀ Ṣàngó lọ ṣètùtù lójúbọ Ṣàngó, gbogbo olùsìn, Ṣàngó ń kì í ní mẹ́sàn-án mẹ́wàá báyìí pé:

Àjàlá ìjí, Baálẹ̀ Kòso
Iná lójú, iná lẹ́nu!
Ọkọ mi di bùlà
Bíná jó láàrò!
Bí yóò bá wọn jà,
A yan lọ bí Ẹdẹ bí Ẹdẹ
Ọkọ̀ọ̀ mi o!
Ará Ogunmọso!
A rìn lọ bí Èjìgbò bí Èjìgbò
Ìwátá ara ìlú Ọ̀yán
Kó tó dé, oníjà gbàgbé,
Òùnlàjà a sì ti sùn!
Àgbáǹgúdú ọrun tí í fọsán jà
Ó jà, jà fọrun tì l'Ẹ́gbẹ̀
Olójú orógbó

Kọ̀lá lo ó jẹ o o jobì

Atọ̀run wá jó bàtá láyé (o.i. 56)

**Ìṣàmúlò Ewì Àwíṣe̩ nínú *Ọmọ Aláte̩ Ìlẹ̀kẹ̀***

Nínú àwọn ọ̀rọ̀ àwíṣẹ Yorùbá, àwọn mẹ́rin ló máa ń rìn papọ̀, àwọn náà ni ọfọ̀, ògèdè, ààsán àti àyájọ́. Nínú àwọn mẹ́ẹ̀ẹ̀rin wọ̀nyí, ọfọ̀ àti ògèdè ló súnmọ́ra pẹ́kípẹ́kí jù lọ, ó sì ṣòro láti yà wọ́n. Fọlọrunṣọ (1982) gbà pé ọfọ̀ náà ni Yorùbá ń pè ní ògèdè. Adeniji (1982) pín ọfọ̀ sí méjì, ọfọ̀ rere àti ọfọ̀ búburú, ó ṣàlàyé pé ọfọ̀ búburú ni ògèdè tí kò dára láti máa pè ṣeré nítorí àpẹ̀yìndà rẹ̀. Ààsán yàtọ sí ọfọ̀ nítorí èdè inú rẹ̀ le, a kì í dédé lo ààsán, nígbà tí ọ̀rọ̀ bá le tán lójú ogun ni a tó máa ń lò ó (Ọdẹjọbi, 2001, o.i. 92). Inú ẹsẹ-ifá ni àyájọ́ ti wá, ọfọ̀ a sì máa wà nínú rẹ̀. Àyájọ́ a máa rọ́ ìtàn pẹ̀lú ìṣàmúlò orúkọ àṣírí. Àyájọ́ so mọ́ òrìṣà kan pàtó. Láwuyì Ogunniran mọ àwíṣẹ Yorùbá dáàyè kan gbogbo rẹ̀ ni a bá pàdé nínú eré *Ọmọ Aláte̩ Ìlẹ̀kẹ̀,* ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé ìtàn tó rọ̀ mọ́ ìtàn ogun àti ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ni. Àwọn ìlò èdè inú ọfọ̀, ààsán àti àyájọ́ kò gbọdọ̀ gbẹ́yìn nínú ogun, fitafita lọ̀rọ̀ ọfọ̀ àti àyájọ́ ń jade tó ń kọlu ra wọn tó sì ń fi agbára tó ń bẹ nínú èdè Yorùbá hàn . Lójú ìwé kejìlélógún Awùjalè ń sọ̀rọ̀, ó ń pọfọ̀ láti gbógun ti Owu, ó fẹ́ kí Òwu ó ṣìṣe ṣùgbọ́n kò sọ ní gbólóhùn kan, ọ̀rọ̀ wúwowúwo, ọ̀rọ̀ tó lóòrìn, ọ̀rọ̀ gbankọgbì láti inú ọfọ̀ ló fi gbé èrò inú ọkàn rẹ̀ jade, ó ní:

Ṣìṣẹṣìṣe níí ṣewúrẹ́

Téwúrẹ́ fi í gùn'ýàá rẹ̀

Ṣìṣẹṣìṣe ní í ṣàgbò

Làgbò fi í gùn'yàá rẹ̀

Ṣìṣẹṣìṣe ní í sòbúkọ

Tí í fi gùn'yàá rẹ̀,

Ṣìṣẹṣìṣe kó máa b'Olówu

Ṣìṣẹṣìṣe kó máa b'Akọgun Òwu

Ṣìṣẹṣìṣe kó máa bọ́mọ ogun Òwu (o.i.22)

Nígbà tí yóò fi parí kò sọ pé kí àṣẹ kó gorí rẹ̀ lásán, ọfọ̀ ló tún fi tẹ̀ ẹ́, ó ní:

Wéréwéré làṣẹ ipín=ín múgbá

Wàràṣesà làṣẹ ọnà-án mẹ́sẹ̀

Àṣẹ t'Akíntólú bá pa fúnlẹ̀

nilẹ̀ gbọ́………

Awùjalẹ̀ tún pọfọ̀ sí, ó ń fi ọ̀rọ̀ Olówu lọ Oòduà, ó wí pé:

Má jẹ́lé Òwu ó rójú

Nítorí pé,

Ọ́rọ́ agogo kì í rójú pewé
Ẹ̀là ìlẹ̀kẹ̀ kì í rójú àtokùnbọ̀,
Àìrójú àìráyè kó lọ sọlẹ̀ s'Owu
Àṣẹ wàá- kí ó rí bẹ́ẹ̀
Takẹ́sẹ ní ṣẹ láwùjọ òwú.. (o.i.23)

Nínú ayọlò yìí, a rí agbára ọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ tó wúwo, a rí ẹwù àti ẹwà èdè Yorùbá, onírúurú àwítúnwí tó ń jálu wọn, 'wéré, wéré'wàràǹṣesà''múgbá'mẹ́sẹ̀' ṣe àfihàn ìṣewẹ́kú tó ń fún èdè Yorùbá  ní adùn. Olówu náà fa ìwo àṣẹ kan yọ, ó ń sọ̀rọ̀:

Òwu alágbára ńlá!
Òwu ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ nílẹ̀ Oòduà
Òwu ni wọ́n pàmọ̀pọ̀
Tí wọ́n fọ́lẹ́ rẹ̀ láìṣebi!
Ogun ni yóò pa wọn dandan,
Ọ̀tẹ̀ ni yóò pa wọ́n dandan.
Ìlú Aláàfin yoò tú ú
Ogun ni yóò pa wọ́n dandan
Ìlú Ẹ̀gbá yóò tú ú,
Ìlú  gbogbo Ẹ̀gbá yóò dahoro
Ilẹ̀ Ẹ̀gbá yóò di tẹlòmíìn
Ìlú Ìjẹ̀bú kò ní gbèrú,
Tifẹ̀ ò níí fẹ̀ sí i
Àìrójú àìráyè ni ó máa bá wọn wọ̀yá ìjà
Agbára lọ́wọ́ Ẹgbẹji ile Òwu (o.i. 54)

Ọ̀nà-Mọgbà náà ki ọfọ̀ bọnu ní Ọ̀yọ́ kí Aláàfin Olúewu lè ṣẹ́gun àwọn Fulani tó dìde ogun sí i láti Ìlọrin, ó ń bọ òrìṣà Ṣàngó, ó sì ń pọfọ̀ báyìí pé:

Ó wáa dolúgììrì wò ó
Orí ọ̀gán lọ̀gàn-án rà sí
Alájogun ló bá ń pe K'oluewu ma rójú,
Ó dolúgììrì wò ó!
Pọ́nkán lorí òkú wọ́n
Wẹ̀rẹ̀ lọmọ ẹ̀yìn-ín gbọ̀n
Ọ̀kọ̀ọ̀kan èjèèjì lọmọ ọwọ̀ yọ (o.i.62)

Tí a bá ṣe àkíyèsí àwọn àpẹẹrẹ méjì òkè wọ̀nyí, a ó rí pé ọfọ̀ tó jẹ́ kìkìdá èpè ni. Èpè jẹ́ ọ̀nà kan tí àwọn Yorùbá máa ń gbà lo èdè lọ́nà òdì láti fi yaró ẹni tó bá ṣẹ̀ wọ́n. Èpè ni ọ̀rọ̀ òdì tí a sọ sáyé ẹlòmíràn láti fa ibi fún un. Bí Olówu ti ń ṣẹ èpè lé ìran Yorùbá gbogbo, ni Ọọni Ifẹ̀ ń ṣẹ́ èpè tirẹ̀ lé Òwu lórí tí wọ́n sì ń fi àṣẹ banu.

**Ìṣàmúlò Orin nínú Eré náà**

Òǹkọ̀wé fi ìlò orin ṣe kísà nínú eré yìí. Ó mú ká rí onírúurú ipa tí orin ń kó nínú eré-onítàn ajẹmọ́ ìmọ̀-ìtàn nítorí nínú orin ọ̀pọ̀ ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ àti ìtàn ló forí mù síbẹ̀. Bí orin ti jẹyọ ni ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ ń tèle nínú eré náà. Ìran Yorùbá fẹ́ràn orin púpọ̀, wọn a máa kọrin nígbà ayọ̀ àti ìgbà ìbànújẹ́, nígbà ayẹyẹ tàbí nígbà ọ̀fọ̀, orin òwe, orin ọ̀tẹ̀, orin ogun àti orin ìgbádùn, orin ẹ̀fẹ̀ àti orin tí a fi ń yin ènìyàn tí orí rẹ̀ á wúlé àti orin èébú tí a fi yẹ̀yẹ́ ẹni. Oríṣiríṣi orin ni òǹkọ̀wé lò nínú eré yìí gẹ́gẹ́ bí ìlò èdè, ìgbékalẹ̀ eré, ìfiwàwẹ̀dá àti ìgbádùn òǹkàwé. Nígbà tí àwọn ajínigbé kọ́kọ́ ń ṣoro, tí wọ́n ń jí àwọn Ọ̀yọ́ gbé tí wọ́n sì ń tà wọ́n lọ́jà Apomù, Orin ẹ̀fẹ̀ ni wọn ń kọ sí àwọn ẹrú kí wọ́n lè máa dá àwọn òyìnbó lára yá kí wọ́n tó rà wọ́n, ọ̀kan lára irú orin bẹ́ẹ̀ ni:

Gàmbàrí, Dìde o jó  
Ogun ló mú'yàá ẹ t'Ilọrin wá  
Gàmbàrí! Dìde o jó  
Ogun ló mú'yàá ẹ t'Ilọrin wá.

Wọ́n kọjá lọ sọ́dọ̀ ọkùnrin tó rí gìdìgbà, wọ́n ń fi ṣe yẹ̀yẹ́, wọ́n ń fẹnu lùlù fún un láti jó

Panbọbọrìgìdá, ẹkọọ Jẹ̀bú  
Panbọbọrìgìdá, ẹ̀kọọ Jẹ̀bú (o.i. 4)

Orin ẹ̀fẹ̀ jẹ́ ọ̀nà kan pàtó tí àwọn akónilẹ́rú àti amúnisìn ń gbà láti tàbùkù àwọn adúláwọ̀ nínú òwò ẹrú. Ìtàn-ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá fi hàn pé fífi ènìyàn ṣẹ̀fẹ̀ máa ń dá ogun sílẹ̀, irú èyí tí a rí lọ́jà Apòmù. Kí ogun tó wáyé láàárín àwọn Ìjẹ̀bú, Ifẹ̀ àti Ẹ̀gbá, orin adájàsílẹ̀ ni orílẹ̀ kọ̀ọ̀kan ń kọ búra wọn, orin òwe ni. Àwọn Òwu ló kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ orin báyìí pé:

Ẹnikan lèṣù ó ṣe (lẹ́ẹ̀méjì)  
Kájá ó dúró  
Kí kookò ó dúró  
Ẹnikan lèṣù ó ṣe

Àwọn Ifẹ̀ gbé orin tiwọn:

Ó dolúfẹrẹkúfẹ  
Ẹ̀rù la fi ń dá bara wa  
Bó lè dogun, kó dogun  
Bó lè dìjà kó dìjà

Akọgun Òwu tún kọ orin òwe mìíràn:

Bẹ́ ẹ pẹ́ẹ̀ dúró ẹ ríṣe wa…..  
Lẹ́ẹ̀kan yìí kọ́

Ká pẹ́lẹ́ṣìnrìn ni ó pa irú àwa

Lẹ́ẹ̀kan yìí kọ́

Orímádégún, baba Títílọlá

Lẹ́ẹ̀kan yìí kọ́ (o.i. 10-11)

Bí eré ṣe ń tẹ̀ síwájú, orin òwe ń dorin èébú, orin èébú ń dorin ìjà. Ní ọjà Apòmù àìgbọ́ra-ẹni-yé kan ṣẹlẹ̀ láàárín ọkùnrin Òwu àti obìnrin Ìjẹ̀bú tó ń ta ataare, ọkùnrin Òwu kọrin èébú pé:

Ojú olè rèé, olè!

Ojú olè rèé, olè!

Ewúrẹ́ eléwúrẹ́, olè!

Àgùtàn alágùtàn, olè!!

Aṣọ aláṣọ, olè!!!

Ọ̀rọ̀ dọ̀rọ̀ ìjà, Ifẹ̀ tó wà lọ́jà Apòmù ran Ìjẹ̀bú lọ́wọ́, òkìkí ìjà náà kàn bá Akọgun Òwu ní ìsàlẹ̀ ọjà, ó mú ọmọkùnrin lẹ́yìn láti wá parí ìjà, ó la àwọn tó ń jà, ọmọ Akọgun Òwu ṣubú lu igbá iyọ̀ obìnrin Ijẹ̀bú, ìyá oníyọ̀ na ọmọ Akọgun Òwu, inú bí Akọgun Òwu pé wọ́n na ọmọ òun játijàti, ó fa àdá yọ ó sì pa obìnrin Ìjẹ̀bú. Alubẹ̀ǹbẹ́ Òwu bẹ̀rẹ̀ orin báyìí pé:

Àgbà Ìjẹ̀bú sorí kẹ̀rẹ̀bútú

Kẹ̀rẹ̀bútú, kẹ̀rẹ̀bútú,

Àgbà Ìjẹ̀bú sorí kẹ̀rẹ̀bútú

Bẹ́ ẹ bá fojú kan Ìjẹ̀bú

Tẹ́ ẹ fojú kan ejò

Ẹ bẹ́rí Ìjẹ̀bú, ẹ fejò sílẹ̀! (o.i. 19)

Orin òwe àti orin èébú wá kúkú dorin ogun, àwọn Ifẹ̀ múra ogun, wọ́n dojú kọ àwọn òwu, wọ́n ń kọrin pé:

Àkéké tí ń kégi

Orí ara rẹ̀ ló ń ké

Ẹ̀lúlùú tó ń pòjò

Orí ara a rẹ̀ ló ń pè

Wómùwómù, ò, orò, máa ké

Gbégbáajé Ifẹ̀ lá a mówu dèmọ́lẹ̀ (o.i. 28)

Àwọn Òwu náà bú sorin ogun tó lágbára láti fi hàn pé wọ́n ti gbaradì fún ogun.

Akínjọbí ń palẹ̀ ogun mọ́,

Òrìṣà, má jẹ́ ó tẹnu mi bọ́

Ajíbíkẹ̀ẹ́, ń palẹ̀ ogun mọ́,

Òrìṣà má jẹ̀ẹ́ ó tẹnu mi bọ́

Oníbẹ̀ǹbẹ́ fìlù sí, orin mìíràn tún jábọ́:

Kẹ́ ẹ forí sọlẹ̀!
Ẹ ti kú!
Kẹ́ ẹ forí sọlẹ̀! (o.i. 32)

Nígbà tí àwọn jagunjagun kọlura lójú ogun, orin yípadà pẹ̀lú ìlù tó le:

Akéréburú ọmọ jọjọlọlá
Àwọn dà?
Àwọn tó ń pera wọn ní nǹkan pàtàkì,
Àwọn dà
Lílé: Àṣé kò le jà!
Ègbè: Títóbi ló tóbi bàǹtù bantu
Ó fikú ṣeré o, ó ń fikú ṣeré
Agẹdẹgúdù, ó ń fikú ṣeré
Lílé: Ó ń polówó o, ó ń polówó
Ègbè: Ẹléko ọ̀run ń polówó
Lílé: Àkùkọ Olówu,
Ègbè: Ọmọ Olówu ni o rèé pa…(o.i. 46)

Lẹ́yìn tí àgbáríjọ Ifẹ̀, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú ṣégun Òwu tán, ẹ̀ka-èdè Ifẹ̀ ni orin tí àwọn Ifẹ̀ ń kọ, orin àdámọ̀ pé:

Orúkọ mẹ́ta lÓwu mà mí jẹ́ (ẹ̀ẹ̀méji)
Òwu dógun sílẹ̀
Ó tún mí jagun
Ibi án rò tẹ́lẹ̀
Logun lé ‘ọn dé o, tọmọtọmọ
Àbùkù kan akàn, ó gbógun tomi
Àbùkù kan akàn kò bómi ṣe mọ́ (o.i. 82)

Bí eré ti ń tẹ̀ síwájú, ogun ń jálu ogun, ọ̀tẹ̀ ń jálu ọ̀tẹ̀. Òǹkọ̀wé mú ká rí ipa tí àwọn ọba kó nínú ogun àti ọ̀tẹ̀. Àwọn ọba ló pàṣẹ fún àwọn akọgun wọn láti ṣígun. Èyí ni pé gbogbo ogun àti ọ̀tẹ̀ tó ja ilẹ̀ Yorùbá, àwọn ọba mọ̀ nípa rẹ̀. Àwọn ọba Yorùbá ló ń ta ọmọ Yorùbá lẹ́rú fún àwọn òyìnbó. Àti gbogun ìlú Yorùbá sí ìlú Yorùbá mìíràn kò sẹ̀yìn àwọn lọ́balọ́ba ilẹ̀ Yorùbá. Gbogbo ewì alohùn tó ṣúyọ nínú eré náà kò wà fún gbẹ̀fẹ́ tàbí ìgbádùn lásán bíkòṣe fún ogun àti ọ̀tẹ̀.

Gbogbo rògbòdìyàn tó ṣẹlẹ̀ nínú eré náà ni òǹkọ̀wé lò láti mú ká rí òfò àti àdánù tí Yorùbá fi ṣera wọn. Òǹkọ̀wé lo Ẹ̀yìnlàárò tí í ṣe Oòduà láti ránṣẹ́ pàtàkì sí ìran Yorùbá lónìí, onírúurú ọgbọ́n ló sì lò láti fi èrò rẹ̀ ránṣẹ́ sí àwùjọ, ó lo òwe, ó lo ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀, ó sì lo orin láti parí ìjà tó ń bẹ láàárín àwọn ọba. Ẹ̀yìnlàárò ki ìpọ̀nrí ọba kọ̀ọ̀kan fún un, ó sì là á mọ́

wọn láyà pé Yorùbá ti sọra wọn di ṣìkàṣìkà, wọ́n gbàgbé alájọbí, wọ́n sọra wọn di adánilóró, wọ́n ti gbàgbé ọ̀la. Orin ló fi wa kókó-ọ̀rọ̀ náà gúlẹ̀ pé kò sí àṣegbé, gbogbo ohun tí a bá ṣe lónìí, ìtàn ni yóò dà lọ́la. Ó kọrin báyìí pé:

Ẹni bá fẹ́ kó ṣayé e re

Ẹni bá fẹ́ kó ṣayé e re o

Yóò ba níbẹ̀ dandan ni

Ẹni  bá fẹ́ kó gbinṣu re

Ẹní bá fẹ́ kó gbinṣu re o,

Yóò jẹ níbẹ̀ kó tó lọ

Ẹni bá fẹ́ kó ṣiṣẹ́ e re

Ẹni bá fẹ́ kó ṣiṣẹ́ e re o

Yóó mà f``abọ̀ f'Ólọ́run (o.i. 73)

Ẹ̀yìnlàárò fi ìran Yorùbá hàn bí arungún ọmọ. Ó bi wọ́n léèrè ọ̀rọ̀ ní ojú-ìwé (73),ó ní:

Ṣé gbogbo ilẹ̀ tẹ́ ẹ jogún lọ́dọ̀ Oòduà, ṣé ọmọ rẹ̀ ló ń jọba lórí

gbogbo rẹ̀ pátá: Ṣé Tápà kò sí, Ìbíní kò sí? Ogun tó wọgbó Àkókó

ilẹ̀ Ọ̀wọ̀, àti Èkìtì ń kọ́? Tí Tápà, Fúlàní àti Ìbíní ń kó wọn bí ọmọ eyẹ;

ǹjẹ́ ẹ fẹ̀lẹ̀koko àtẹ̀rọ̀pẹ̀sẹ̀ dojú kọ ìjà náà?

Ẹ̀yìnlàárò lo àyọlò yìí láti rán ònkàwé létì ìtàn ilẹ̀ Yorùbá. Ṣáájú ìṣubú ilẹ̀ Yorùbá, ọlá, agbára àti ìjọba ilẹ̀ Yorùbá pọ̀ jaburata, ó dé ilẹ̀ Tápà, Bàrìbá, Ìdọ̀ọ̀mì àti ilẹ̀ Àgànyìn (Ghana), ṣùgbọ́n nítorí ìwà ìmọtara-ẹni nìkan àti àìnífẹ̀ẹ́, agbára bọ́ lọ́wọ́ wọn, àwọn tí wọ́n jọba lé lórí bọ́ sọ́wọ́ Fúlàní àti Ìbíní nítorí inú líle àti àìsí ẹ̀mí ìṣọ̀kan. Ní ìgbẹ̀yìn, Ẹ̀yìnlàárò ṣá ọ̀rọ̀ mọ́ gbogbo wọn láyà, wọ́n túúbá, wọ́n pinnu láti yípadà kúrò nínú ìwà ibi wọn kí ilẹ̀ Yorùbá lè rójú ráyè tẹ̀ síwájú. Gbogbo wọn fi orin ìṣọ̀kan parí ìjà àti àsọ báyìí pé:

Oníkálukú, ó dọwọ́ọ̀ rẹ;

Ọ̀mọ̀ràn-Ifẹ̀, ó dọwọ́ọ̀ rẹ;

Ọlọ́gbọ́n-Ọ̀yọ́, ó dọwọ́ọ̀ rẹ;

Ọmọ Awùjaalè, ó dọwọ́ọ̀ rẹ;

Ọmọ Ẹ̀gbáláké, ó dọwọ́ọ̀ rẹ;

Ẹ wí fúnra yín, ó dọwọ́ àwa o!

Baba ti sọ̀rọ̀, ẹ jẹ́ ká gbọ́. (o.i.91)

**Ìkádìí**

Onírúurú èròjà láti inú ewì alohùn Yorùbá ni Alàgbà Láwuyì Ògúnniran lò láti dín ọbẹ̀ eré *Ọmọ Aláṭẹ Ìlẹ̀kẹ̀* tó gbẹ tọ́kí, tó sì dùn mọ̀rànyìn-mọranyin. Ọ̀pọ̀ irú kì í ba ọbẹ̀ jẹ́. Ọ̀pọ̀ èròjà ewì alohùn Yorùbá tó lò bí òwe, oríkì, ọfọ̀, ayájọ́, àti orin mú adùn tó ga bá eré náà. Ẹ̀yà ewì kọ̀ọ̀kan ló kún fún ọ̀rọ̀ tó gbórín, tó lóòrìn tó jinlẹ̀. Àwọn àgbà ló jẹ́ akópa nínú

eré, ọ̀rọ̀ àgbà ló ń jade lẹ́nu wọn, ọ̀rọ̀ àgbọ́mirí, ọ̀rọ̀ àṣehùn un tó so mọ́ ìtàn ilẹ̀ Yorùbá. Òǹkọ̀wé lo ewì alohùn Yorùbá fún ìgbékalẹ̀ àti ahunpọ̀ ìtàn rẹ̀, ète ìfìwàwẹ̀dá, kókó-ọ̀rọ̀ àti ìlò èdè. Ó jẹ́ kí eré náà ó dùn-ún kà, adùn èdè, àti adùn ìtàn tí ó fi ewì alohùn gbékalẹ̀ mú kí òǹkàwé gba Láwuyì Ogúnniran lọ́gàá, nítorí pé ọ̀nà kan pàtàkì láti dáàbòbo ewì alohùn Yorùbá ni ìṣàmúlò rẹ̀ nínú eré onítàn Yorùbá òde-òní.

Òǹkọ̀wé mú kí eré náà parí tẹ̀rín tẹ̀rín, tayọ̀tayọ̀, eré tó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ẹkún àti ọ̀fọ̀ parí sí ẹkúndẹ̀rín ṣùgbọ́n gbogbo ègún àti èpè tí àwọn ọba gbéra wọn ṣẹ́ pàápàá ègún Olówu, Ọọni Gbégbáajé wà níbẹ̀ digbí, ó yẹ kí Ẹ̀yìnlàáró ré ègún náà padà nítorí ègún jà ju èpè, èpè jẹ́ ju òògùn lọ. Ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Aláàfin Aólẹ̀ náà gbé ìran Yorùbá gégùn ún kí ó tó ṣígbá, kò tíì sí ẹni tó ré ègún náà dànù títí dì òní. Ìkádìí rẹ̀ ni pé òpìtàn pàtàkì ni Alàgbà Láwuyì Ogunniran, akéwì ìsẹ̀ǹbáyé tó jinlẹ̀ nínú ewì alohùn Yorùbá ni, ó sì fi ìwé *Ọmọ Aláte̩ Ìlẹ̀kẹ̀* pàrokò sí ìran Yorùbá pé kí wọ́n jáwọ́ lápọ̀n tí ò yọ̀, kí wọ́n gbómi ilá kaná, kí wọ́n wà ní ìrẹ́pọ̀ láìjà mọ́, kí ọ̀mọ aláte̩ ìlẹ̀kẹ̀ má bàá dọmọ aláte̩ ọ̀rúnlá àti pé kí ewì àlohùn Yorùbá ó wà títí láé fún ìran tó ń bọ̀ lẹ́yìn.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Adebisi, A. (2001), Lítíréṣọ̀ alohùn àti ọgbọ́n ìkọ́ni, *Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Aṣà, Ilẹ̀ Nàìjíríà,* 3 (1),60-68.

Adejumọ, A. (2011). Text and inter-textuality in contemporary Yorùbá literary works. In Toyin Falọla and Adebayo Oyebade (eds). *Yorùbá fiction, orature and culture, Oyekan Owomoyela and African literature and the Yorùbá experience*. New Jersey: Africa World Press,209-222.

Adeniji, A.A. (1982). *Ọfọ̀ rere*. Ibadan: University Press.

Adeyemi, L. (2011). Politics and proverbs in selected Yorùbá novels. In Toyin Falọla and Adebayo Oyebade (eds). *Yorùbá fiction, orature and culture, Oyekan Owomoyela and African literature and the Yorùbá experience*. New Jersey: Africa World Press, 183-208

Adeyemi, L. (2001). The oratory style of Lawuyi Ogunniran in Ọmọ Alate̩ Ìlẹ̀kẹ̀ . In *Yorùbá: A journal of the Yorùbá Studies Association of Nigeria* 2 (1), 73-89.

Akínyẹmi, A. (2011). Nigerian contemporary dramatists and the art of court praise singing. In Toyin Falọla and Adebayo Oyebade (eds). *Yorùbá fiction, orature and culture, Oyekan Owomoyela and African literature and the Yorùbá experience*. New Jersey: Africa World Press,3-26.

Arohunmọlaṣẹ, O. (2001). Lítíréṣọ̀ alohùn àti ètò ìṣèlú: Ìlò lítíréṣọ̀ alohùn nínú àwọn eré-onítàn kan bí àpẹẹrẹ. *Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àsà Yorùbá, ilẹ̀ Nàìjíríà*, 3 (1),37-44.

Bámgbóṣé, A. (1974). *The novels of D.O. Fágúnwà*. Benin: Ethiope Publishing Corporation.

Bámgbóṣé, A. (2007). *The novels of D.O. Fágúnwà*: *A commentary*. Ìbàdàn: Nelson Publishers.

. Bohrer, S.P. and Susanne Wenger, A. (1976). “Gods and Myths in Susanne Wenger’s Art: The Example of a Batik Cloth”. *Nigeria Magazine,* 120 (1976):12.

Greenblatt, S. (1992). The forms of power and the power of forms in the renaissance. *Genre*, 15, 1-6.

Fọlọrunṣọ, A.O. (1982). Àyẹ̀wò Ewì Àbáláyé, M.A. Dissertation, Ile-ifẹ: University of Ifẹ. Ikudaisi, O. (1980). Òwe Yorùbá. *Yorùbá Gbode*, No 5, 27-31.

Ọdẹjọbi, C.O. (2001). Ìlò ohun àbáláyé nínú fíìmù àgbéléwò Yorùbá “Ègún Àìmọ̀”láti ọwọ́ Sọla Mike Agboọla. In *Yorùbá A journal of the Yoruba Studies Association of Nigeria*, 2 (1), 90-101.

Ogundeji, P.A. (1992). O literature in Yorùbá novels. *African Notes: Journal of the Institute of African Studies,* University of Ibadan, xvi (1 & 2),23-31.

Ogunniran, L. (1992). *Ọmọ Aláte̩ Ìlẹ̀kẹ̀*. Ibadan: Lolyem Communication.

Ògúnṣínà, B. (1987). The sociology of the Yorùbá novel: A study of Isaac Thomas, D.O. Fágúnwà and Ọládẹ̀jọ Òkédìjí. Unpublished Ph.D.,

Ìbàdàn: University of Ìbàdàn.
Ògúnṣínà, B. (1992). *The development of the Yorùbá novel (1930-1975).* Ìbàdàn: Gospel Faith Mission.
Ọlábímtán, A. (1975). Religion as a theme in Fágúnwà Novels. *Odu 11*, pp. 301-310.
Ọlabimtan, A. (1980). Ètò àti ìlànà ẹ̀kọ́ ewì Yorùbá ni ilé-ìwé giram àti ti ẹ̀kọ́ṣẹ́ olùkọ́. *Yorùbá Gbòde,* No 5, 98-106.
Olajubu, O. (1978). Oríkì. *Yorùbá Gbòde*, 2 (3),15-27.
Ojaide, T. and T.M. Sallah (eds). (1999). *The new African poetry: An anthology*. London: Lynne Rienner.
Okpewho, I. (1992). *African oral literature: Backgrounds, characters, and continuity*. Bloomington: Indiana University Press.
Olatẹju, A. (1999). The language of Yorùbá drama: Adebayo Faleti's Basọrun Gaa as a case study. In papers in honour of Prof. Adelugba at 60, edited by Egbe Ifie, 276-293.
Raji, S.M. (1991). *Ìjìnlẹ̀ ọfọ̀, ògèdè àti àásán*. Ibadan: Onibọnoje Press and Book Industries (Nig) Ltd.

Recebido em: 23/02/2025

Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** ADÉYẸMÍ, jọ̀gbọ́n Ọlálérè. Ewì Alohùn Nínú Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá: Ìwé Eré-onítàn *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* tí Láwuyì Ògúnniran kọ bí Àpẹẹre. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p.11-32, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Adéyẹmí, jọ̀gbọ́n Ọlálérè. (jan./jun.2025). Ewì Alohùn Nínú Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá: Ìwé Eré-onítàn *Ọmọ Aláte Ìlẹ̀kẹ̀* tí Láwuyì Ògúnniran kọ bí Àpẹẹre. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 11-31.